66

# ÌFIHÀN TI JOHANU

**(A.D. 96)**

ORI 1.

**Ifihan ti Jesu Kristi tí Ọlọrun fifun un.**

IFIHAN ti Jesu Kristi, ti Ọlọrun fi-
fun un, lati fihan fun awọn ìránṣẹ́ rẹ̀
ohun ti yoo ṣẹlẹ̀ ni lọ́ọ́lọ́ọ́; o si ranṣẹ, o
si fi i hàn lati ọwọ angẹli rẹ̀ wá fun Jo-
hanu, iranṣẹ rẹ̀: (Jhn 12:49; Ifh 22:
16.)
2. Ẹni ti o jẹri ọrọ Ọlọrun, ati ẹri
Jesu Kristi, ati ti ohun gbogbo tí o rí.
(1 Kor 1:6; Ifh 12:17.)
3. Olùbùkún ni ẹni ti nkà, ati awọn
ti o ngbọ ọrọ isọtẹlẹ yìí, ti o si npa
nkan wọnyìí ti a kọ sinu rẹ̀ mọ́: nito-
ri igba kù si dẹ̀dẹ̀. (Luk 11:28; Ifh
22:10.)

**Ọ̀rọ̀ Ìkíni.**

4. Johanu sí Ìjọ meje ti nbẹ ni Asia:
Oore-ọfẹ fun yin, ati alaafia, lati ọ̀dọ̀
ẹni ti o nbẹ, ti o si ti wà, ti o si nbọ̀wá;
ati lati ọ̀dọ̀ awọn Ẹmi meje ti nbẹ ni-
waju ìtẹ́ rẹ̀; (Jhn 1:1; Ifh 3:1; 4:5.)
5. Ati lati ọ̀dọ̀ Jesu Kristi, ẹlẹri
olóòtọ́, akọbi ninu awọn òkú, ati aláṣẹ
awọn ọba ayé. Ẹni ti o fẹ́ wa, ti o si wẹ̀
wá ninu ẹ̀jẹ̀ rẹ̀ kuro ninu ẹ̀ṣẹ wa. (Ifh
3:14; Kol 1:18; Psm 89:27; Ifh 17:
14; Jhn 13:34; Heb 9:14.)
6. Ti o sì ti fi wá jẹ ọba ati alufa fun
Ọlọrun ati Baba rẹ̀; Tirẹ̀ ni ogo ati
ijọba lae ati laelae. Amin. (1 Pet 2:5;
Ifh 5:10; Rom 11:36.)
7. Kiyesi i, o nbọ̀ ninu ìkùukùu àwọ-
sánmà; gbogbo oju ni yoo sì ri i, ati
awọn ti o gun un ni ọ̀kọ̀ pẹlu; ati
gbogbo orilẹ-èdè ayé ni yoo si maa
pohùnréré ẹkún niwaju rẹ̀. Bẹẹ naa ni.
Amin. (Sek 12:10.)
8. "Emi ni Alfa ati Omega, ipilẹ̀ṣẹ̀
ati òpin", ni Oluwa wí, ẹni ti o nbẹ, ti o
ti wà, ti o si nbọ̀wá, Olodumare. (Ifh
21:6; 4:8; 16:7.)

**Ohùn ati ìran naa.**

9. Emi Johanu arakunrin yin ati
alabapín pẹlu yin ninu ipọnju ati ijọba,
ati suuru ti nbẹ ninu Jesu, wà ninu
erékùṣù ti a npe ni Patmo, nitori ọ̀rọ̀
Ọlọrun, ati nitori ẹ̀rí Jesu Kristi. (Filp
4:14.)
10. Mo wà ninu Ẹ̀mí ni ọjọ́ Oluwa,
mo sì gbọ́ ohùn nla kan lẹhin mi, bi ìró
ìpè. (Ifh 4:1,2.)
11. O nwi pé, "Emi ni Alfa ati Ome-
ga, ẹni-iṣaaju ati ẹni-ìkẹhìn: ohun ti
iwọ bá sì rí, kọ́ ọ sinu iwe, ki o si
ran an si awọn ijọ meje; si Efesu, ati si
Smirna, ati si Pergamu, ati si Tiatira,
ati si Sardi, ati si Filadelfia, ati si
Laodikea." (ẹsẹ 8,17.)
12. Mo sì yipada lati wo ohun ti nba
mi sọ̀rọ̀. Nigba ti mo yipada, mo ri ọ̀pá
fitila wura meje; (Eks 25:27; Sek 4:2.)
13. Ati laarin awọn ọ̀pá fitila naa,
ẹnikan ti o dabi Ọmọ eniyan, ti a wọ ni
aṣọ ti o kanlẹ̀ de ẹsẹ̀, ti a si fi àmùrè
wúrà di lẹ́gbẹ̀ẹ́; (Esk 1:26; Dan 7:13;
10:5.)
14. Ori rẹ̀ ati irun rẹ̀ funfun bi ẹ̀gbọ̀n
òwú, o funfun bi òjò-dídì; ojú rẹ̀ si dabi
ọ̀wọ́-iná. (Dan 7:9; 10:6; Ifh 19:12.)
15. Ẹsẹ rẹ̀ si dabi idẹ daradara, bi
ẹnipe a dáà ninu ileru; ohùn rẹ̀ si dabi
iró omi pupọ̀. (Dan 10:6; Esk 43:2.)
16. O si ni irawọ meje ni ọwọ́ ọtún
rẹ̀; ati lati ẹnu rẹ̀ wá ni idà oloju meji
mimu ti jade: oju rẹ̀ si dabi òòrùn ti o
nfi agbara rẹ̀ ràn. (Ifh 2:1; 3:1; Heb
4:12; Ifh 2:12,16.)
17. Nigba ti mo ri i, mo wolẹ ni ẹsẹ̀
rẹ̀ bi ẹni ti o kú. O si fi ọwọ́ ọ̀tún rẹ lé
mi, o nwi fun mi pé, "Má ṣe bẹ̀rù; Emi
ni ẹni-iṣaaju ati ẹni-ikẹhin. (Esk 1:28;
Dan 8:18; 10:10; Isa 41:4.)
18. Emi ni ẹni ti o nbẹ láàyè, ti o si ti
kú; si kiyesi i, emi si nbẹ láàyè si i titi

lae, mo si ni kọ́kọ́rọ́ ikú ati ti Isà-òkú. (Rom 6:9; Ifh 4:9; 20:1.)

19. Kọwe ohun gbogbo ti iwọ ti ri, ati ti ohun ti nbẹ, ati ti ohun ti yoo ṣẹlẹ̀ lẹhin èyí;

20. Ohun ìjìnlẹ̀ ti ìràwọ̀ meje naa ti iwọ ri ní ọwọ́ ọtún mi, ati ọ̀pá fitila wúrà meje naa, Ìràwọ̀ meje naa ni awọn angẹli (iranṣẹ) Ìjọ meje; ati ọ̀pá fitila meje naa ti iwọ ri ní awọn ìjọ meje." (Sek 4:2-6; Ifh 11:4.)

## ORI 2.

**Iṣẹ́ ti a rán si ìjọ meje; bẹ̀rẹ̀ pẹlu ìjọ Efesu.**

SI angẹli (iranṣẹ) ijọ ni Efesu kọwe; 'Nkan wọnyìí ni ọ̀rọ̀ ẹni ti o mu ìràwọ̀ meje naa ni ọwọ́ ọ̀tún rẹ̀, ẹni ti nrìn laarin ọpa wura fitila meje naa pe, (Ifh 1:16; 1:13.)

2. "Emi mọ iṣẹ rẹ, ati làálàá rẹ, ati ifarada rẹ, ati bi ara rẹ kò ti gba awọn ẹni buburu: ati bi iwọ si ti dán awọn ti npe ara wọn ni aposteli, ti wọn kìí sìí ṣe bẹ ẹ wò, ti iwọ sì rí pe elékèé ni wọn. (Ifh 3:8 ; 1 Jhn 4:1; 2 Kor 11:13.)

3. Ati pe iwọ si ní ìfaradà, ati pe ó si nfarádàá nitori orukọ mi ti àárẹ̀ kò sì mú ọ. (Jhn 15:21.)

4. Ṣugbọn èyí ni mo ri wi si ọ, pe, iwọ ti fi ìfẹ́ rẹ iṣaaju sílẹ̀. (Matt 24:12.)

5. Nitori naa ranti ibiti iwọ gbe ti ṣubú, ki o sì ronupiwada, ki o si ṣe iṣẹ́ iṣaaju; bi kò sì ṣe bẹẹ, emi o si tọ̀ ọ́ wá, emi o si ṣí ọpa fitila rẹ kuro ni ipò rẹ̀, bikoṣe bi ìwọ ba ronupiwada. (ẹsẹ 16,22,2; Ifh 1:20.)

6. Ṣugbọn eyi ni ìwọ ni, pe iwọ korira iṣẹ awọn *Nikolaitani eyi tí emi pẹlu si korira. (ẹsẹ 15.)

7. Ẹni ti o ba ni eti jẹ ki o gbọ́ ohun ti Ẹ̀mí nsọ fun awọn ìjọ; 'Ẹni ti o ba ṣẹgun ni emi o fi èso igi ìyè fún jẹ, ti nbẹ laarin Paradise Ọlọrun.'" (Matt 11:15; Ifh 3:6,13; Gen 2:9; 22:2, 14; 2 Kor 12:2-4.)

**Iṣẹ́ ti a ran si Ijọ Smirna.**

8. "Ati si angẹli (iranṣẹ) ìjọ ni Smirna kọ̀wé; 'Nkan wọnyìí ni ẹni ti nṣe ẹni-iṣaaju ati ẹni-ìkẹhìn wí, ẹni ti o ti kú, ti o sì tún yè; (Ifh 1:11; 17:18.)

9. Emi mọ ìpọnjú, ati àìní rẹ (ṣugbọn ọlọ́rọ̀ ni o,) emi sì mọ ọ̀rọ̀-òdì lati ọ̀dọ awọn ti wọ́n wi pe Ju ni wọ́n, ti wọn kìí sìí ṣe bẹẹ, ṣugbọn ti wọ́n jẹ sinagọgu ti Satani. (Ifh 1:9; Jms 2:5; Ifh 3:9.)

10. Má ṣe bẹru ohunkohun ti iwọ nbọ̀ wá jìyà rẹ̀: kiyesi i, Eṣu yoo gbé ninu yin jù sinu túbú, ki a lè dán yín wò; ẹ̀yin o si ni ipọnju ni ijọ́ mẹwa: ìwọ saa ṣe olootọ de ojú ikú, emi o si fi adé ìyè fun ọ. (Ifh 3:10; Dan 1:12.)

11. Ẹni ti o bá leti, ki o gbọ́ ohun ti Ẹ̀mí nsọ fun awọn ìjọ; Ẹni ti o bá ṣẹgun ki yoo farapa ninu ikú keji.'" (Ifh 20:14; 21:8.)

**Iṣẹ́ ti a rán si Ìjọ Pergamu.**

12. "Ati si angẹli (iranṣẹ) ìjọ ni Pergamu kọwe; 'Ọ̀rọ̀ wọnyìí ni ẹni ti o ni idà mímú oloju meji wi pe, (Ifh 1:11,16.)

13. **(Emi mọ iṣẹ́ rẹ,) emi mọ ibi tí iwọ ngbé, ani ibi ti ìtẹ́ Satani wà, ati pe iwọ di orukọ mi mu ṣinṣin, ti iwọ kò si sẹ́ igbagbọ mi, pàápàá julọ ni ọjọ Antipa ẹlẹri mi, olootọ́ eniyan, ẹni ti wọn pa laarin yin, nibi ti Satani ngbe. (Ifh 14:12; ẹsẹ 9.)

14. Ṣugbọn mo ni nkan diẹ wí sí ọ; nitori ti iwọ ní awọn kan ti o di *ẹ̀kọ́ Balaamu mu nibẹ̀, ẹni ti o kọ́ Balaki lati mu ohun ìkọ̀sẹ̀ wa siwaju awọn ọmọ Israẹli, lati maa jẹ ohun ti a pa rubọ si oriṣa, ati lati maa ṣe àgbèrè. (Num 24:14; 2 Pet 2:15; Jud 11; 1 Kor 8:9; 10:19,20; 6:13.)

(6) *(Nikolaitani ni awọn ijọ eniyan tabi awọn eniyan ti o gbàgbọ́ ninu iru-ẹ̀kọ́ odi ti Nikolausi dá silẹ: ẹkọ-odi bẹẹ ni pe bi ẹnikan ba ti gbàgbọ́, ti o si ti ri igbala, ẹṣẹkẹṣẹ ti o ba dá, bii panṣaga, àgbèrè, kiko iyawo jọ, jijẹ ohun-irubọ oriṣa, kìí ṣe ẹṣẹ fun un mọ́.)

(13) **(Awọn Bibeli atijọ miran fi eyi kun tiwọn.)

(14) *Ẹkọ Balaamu ni eyi ti nmu eniyan Ọlọrun di ẹni ifibu niwaju Ọlọrun nigba ti ẹwà awọn obinrin alaigbagbọ bá mu un ṣe agbere ati ojukokoro (tii ṣe ibọriṣa) ti o si nlepa lati di ọlọ́rọ̀ lọ́na àìtọ́ ati àiṣododo gbogbo.

15. Bẹẹ ni iwọ sì ní awọn ti o gba ẹ̀kọ́ awọn Nikolaitani pẹlu, ohun ti mo korira. (ẹsẹ 6.)

16. Ronupiwada; bikoṣe bẹẹ emi o tọ̀ ọ́ wá nisinsinyìí, emi o si fi idà ẹnu mi bá wọn jà. (2 Tess 2:8; Ifh 1:16.)

17. Ẹni ti o bá leti, ki o gbọ ohun ti Ẹmí nsọ fun awọn ìjọ; Ẹni ti o bá ṣẹgun ni emi o fi mánnà ti o pamọ fun emi o si fun un ni okuta funfun kan, ati sára okuta naa ni a kọ orukọ titun kan, ti ẹnikan ko mọ̀ bikoṣe ẹni ti o gba a.'" (Jhn 6:49,50; Isa 62:2; Ifh 19:12; 2 Kor 12:3,4.)

**Iṣẹ́ ti a ran si Ijọ Tiatira.**

18. "Ati si angẹli (iranṣẹ) ijọ ni Tiatira kọwe: 'Nkan wọnyìí ni Ọmọ Ọlọrun wi, ẹni ti oju rẹ̀ dabi ọ̀wọ́ iná, ti ẹsẹ̀ rẹ̀ si dabi idẹ daradara: (Ifh 1:11,14,15.)

19. Emi mọ iṣẹ́ rẹ, ìfẹ́, ati igbagbọ ati ìsìn ati suuru rẹ; ati pe iṣẹ́ rẹ ìkẹhìn ju ti iṣaaju lọ. (ẹsẹ 2.)

20. Ṣugbọn eyi ni mo rí wí si ọ, nitori ti iwọ fi àyè silẹ fun **obinrin Jesebeli ti o npe ara rẹ̀ ni woli, o si nkọ́ awọn iranṣẹ mi ó sì ntàn wọ́n lati maa ṣe àgbèrè, ati lati maa jẹ ohun ti a pa rubọ si òrìṣà. (1 A.Ọba 16:31; 21:25; 2 A.Ọba 9:7; A.A. 15:20; 1 Kor 14: 34–38; 1 Tim 2:11–15.)

21. Emi fi àkókò fun un, lati ronupiwada; kò sì fẹ́ ronupiwada àgbèrè rẹ̀. (Rom 2:4; Ifh 9:20.)

22. Kiyesi i, emi o gbe e sọ si orí àkéte, ati awọn ti nba a ṣe panṣaga ni emi o fi sinu ipọnju nla, bikoṣe bi wọ́n bá ronúpìwàdà iṣẹ́ wọn. (Ifh 17:2; 18:9.)

23. Emi o si fi ikú pa awọn ọmọ rẹ̀; gbogbo ìjọ ni yoo si mọ̀ pe, emi ni ẹni ti nwadi inú ati ọkàn: emi o si fifun olúkúlùkù yin gẹgẹ bi iṣẹ́ rẹ̀. (Jer 11:20; A.A. 1:24; Rom 8:27; Psm 62:12.)

24. Ṣugbọn ẹ̀yin ni mò nsọ fun, ẹ̀yin iyoku ti nbẹ ni Tiatira gbogbo ẹ̀yin ti kò ni ẹ̀kọ́ yìí, ti kòì tí ì mọ̀ ohun ti wọn pe ni ohun ìjìnlẹ̀ Satani, emi kò di ẹrù miran rù yin. (A.A. 15:28.)

25. Ṣugbọn eyi tí ẹ̀yin ní, ẹ di i mu ṣinṣin titi emi o fi dé.

26. Ẹni ti o bá sì ṣẹgun, ati ẹni ti o bá pa iṣẹ́ mi mọ́ titi de opin, emi o fun un láṣẹ lori awọn orilẹ-èdè: (Heb 3:6; Psm 2:8; Ifh 3:21.)

27. Oun o si maa fi ọ̀pá irin ṣe àkóso wọn; gẹgẹ bi a ti nfọ́ ohun-èlò amọ̀-kòkò ni a o fọ́ wọn túútú; bi emi pẹlu ti gba lati ọ̀dọ̀ Baba mi. (Ifh 12:5; Isa 30:14; Jer 19:11.)

28. Emi o si fi ìràwọ̀ owurọ fun un.' (Ifh 22:16.)

29. Ẹni ti o ba létí, ki o gbọ ohun ti Ẹmí nsọ fun awọn ìjọ."

## ORI 3.

**Iṣẹ́ tí a ran si Ìjọ Sardi.**

ATI si angẹli (iranṣẹ) ijọ ni Sardi kọ̀wé: 'Ọ̀rọ̀ wọnyìí ni ẹni ti o ni Ẹmí meje Ọlọrun, ati ìràwọ̀ meje wi pé: "Emi mọ iṣẹ́ rẹ, ati pe iwọ ni orukọ pe iwọ nbẹ láàyè, ṣugbọn iwọ kú. (Ifh 1:4,16; 2:2; 1 Tim 5:6.)

2. Jí, ki o si fi ẹsẹ̀ ohun ti ó kù múlẹ̀, ti o ṣetan lati kú: nitori emi kò ri iṣẹ́ rẹ ni pípé niwaju Ọlọrun.

3. Nitori naa ranti bi iwọ ti gba, ati bi iwọ ti gbọ́, ki o si pa a mọ́, ki o si ronupiwada. Njẹ, bi iwọ kò ba ṣọ́ra, emi o de si ọ bi olè, iwọ ki yoo si mọ wakati ti emi o de si ọ. (1 Tess 5:2,6; 2 Pet 3:10.)

4. Iwọ ni orukọ diẹ ni Sardi, ti kò fi aṣọ wọn yi èérí; wọn o si maa ba mi rìn ni aṣọ funfun: nitori wọ́n yẹ. (A.A. 1:15; Jud 23; Ifh 6:11; 7:9,13.)

5. Ẹni ti o ba ṣẹgun, oun naa ni a o fi aṣọ funfun wọ̀; emi ki yoo pa orukọ rẹ̀ rẹ́ kuro ninu iwe ìyè, ṣugbọn emi o jẹwọ orukọ rẹ̀ niwaju Baba mi, ati niwaju awọn angẹli rẹ̀. (Matt 10:32.)

6. Ẹni ti o ba leti, ki o gbọ́ ohun ti Ẹmí nsọ fun awọn ìjọ.'" (Ifh 2:7.)

---

(20) **O lewu lati gba obinrin láàyè, ninu ijọsin ijọ, lati maa ṣe iṣẹ-woli, lati maa sọtẹ́lẹ̀ tabi maa ṣakoso ijọ, nitori obinrin ni eṣu maa nlo lati mu ijọ Ọlọrun kọsẹ̀. (1 Tim 2:11–15.)

**Iṣẹ́ ti a ran si Ìjọ Filadelfia.**

7. "Ati sí angẹli (iranṣẹ) ìjọ ni Filadelfia kọwe; 'Ọ̀rọ̀ wọnyìí ni ẹni tí o jẹ́ mímọ́ naa wí, ẹni ti o ṣe olootọ́, ẹni ti o ni kọ́kọ́rọ́ Dafidi, ẹni ti o ṣi, ti kò sí ẹni ti yoo tì; ẹni ti o sì tì, tí kò si ẹni ti yoo ṣí i: (A.A. 3:14; 1 Jhn 5:20; Isa 22:22.)

8. Emi mọ iṣẹ́ rẹ: kiyesi i, mo gbe ilẹkun ti o ṣí kalẹ̀ niwaju rẹ, ti kò sí ẹni ti o lè ti í: pe iwọ ni agbara diẹ, iwọ sì pa ọ̀rọ̀ mi mọ́ iwọ kò sì sẹ́ orukọ mi. (A.A. 14:27; Ifh 2:13.)

9. Kiyesi i, emi o mu awọn ti *sinagogu Satani, awọn ti wọn nwi pe Ju ni awọn, ti wọn ki si i ṣe bẹẹ, ṣugbọn ti wọn nṣèké; kiyesi i, emi o mu ki wọn wá wólẹ̀ niwaju ẹsẹ̀ rẹ, ki wọn si mọ̀ pe emi ti fẹ ọ. (Ifh 2:9; Heb 7:18,19; 8:6,7; Tit 1:16; 2 Tim 3:5–9; Kol 2:18–23; 2 Kor 11:12–15; Matt 7: 21–24.)

10. Nitori ti iwọ ti pa ọrọ suuru mi mọ́, emi pẹlu yoo pa ọ́ mọ́ kuro ninu wakati ìdánwò, ti nbọ̀wa de ba gbogbo ayé, lati dan awọn ti ngbe ori ilẹ ayé wo. (2 Pet 2:9; Ifh 16:14; 6:10; 17:8.)

11. Kiyesi i, emi nbọ̀ kankan: di eyi ti iwọ ní mú ṣinṣin, ki ẹnikẹni má ṣe gba adé rẹ. (Ifh 22:7,12,20; 2:25,10.)

12. Ẹni ti o ba ṣẹgun, oun ni emi o fi ṣe ọ̀wọ̀n ninu tẹmpili Ọlọrun mi, oun ki yoo si jade kuro nibẹ mọ́: emi o si kọ orukọ Ọlọrun mi si i lára, ati orukọ ilu Ọlọrun mi, ti i ṣe Jerusalẹmu titun, ti o nti ọrun sọkalẹ lati ọ̀dọ̀ Ọlọrun mi wá: ati orukọ titun ti emi tikarami.' (Gal 2:9; Ifh 22:4; 21:2.)

13. Ẹni ti o bá leti, ki o gbọ́ ohun ti Ẹmi nsọ fun awọn ìjọ." (ẹsẹ 6.)

(9) *Kò si ijọ kan ti o jẹ kọ àkọlé "Sinagọgu Satani" yìí sori ile-isin wọn. Ṣugbọn a ndá wọn mọ nipa ìṣe ati ìlànà ijọsin wọn ti kò bá ihinrere Kristi mu ṣugbọn ti wọn ntẹ̀lé ofin ati ilana Mose (Majẹmu laelae) nitori èrè ti ara. Nipa bayìí, wọn jasi èké nitori wọn kii ṣe Ju (ti a fun lófin) bẹẹ si ni wọn kii ṣe Kristiani (nitori wọn ko tẹle aṣẹ ati ètò ijọsin ti Kristi) ṣugbọn a ntan wọn jẹ lati ọwọ Satani ati awọn iranṣẹ rẹ (èké aposteli, ati eke woli): Ninu ẹtan wọn wọn npe orukọ Jesu lásán. (Ka itọ́kasi-ẹsẹ bibeli ti o wa ni ìpari ẹsẹ 9.)

**Iṣẹ́ ti a ran si Ìjọ Laodikea.**

14. "Ati si angẹli (iranṣẹ) ijọ ni Laodikea kọwé: 'Ọ̀rọ̀ wọnyìí ni ẹni ti njẹ Àmín wí, ẹlẹri òdodo ati olootọ́, olùpilẹ̀ṣẹ̀ ẹda Ọlọrun: (Isa 65:16.)

15. Emi mọ iṣẹ́ rẹ, pe iwọ ko gbóná bẹẹ ni iwọ kò tutù: emi ìbá fẹ́ pe ki iwọ kúkú tutù, tabi ki iwọ kuku gbóná. (ẹsẹ 1.)

16. Njẹ nitori ti iwọ ṣe ìlọ́wọ́wọ́, ti o kò si gbóná, bẹẹ ni o kò tutù, emi o pọ̀ ọ́ jade kuro ni ẹnu mi.

17. Nitori ti iwọ wi pé, Emi ní ọrọ̀, emi si npọ̀sí i ni ọrọ̀, emi kò si ṣe alaini ohunkohun; ti iwọ kò sì mọ̀ pe, òṣì ni iwọ, ẹni-ikaanu, tálákà, afọ́jú, ati ẹni-ìhòhò: (Hos 12:8; Sek 11:5; 1 Kor 4:8.)

18. Emi fun ọ ni ìmọ̀ràn pe ki o ra wura lọwọ mi ti a ti dà ninu iná, ki iwọ lè di ọlọ́rọ̀; ati aṣọ funfun, ki iwọ lè fi wọ ara rẹ, ati kí ìtìjú ìhòhò rẹ má ba hàn ki o si fi ohun ikunra kun oju rẹ, ki iwọ lè riran. (Isa 55:1; Matt 13:44; Ifh 7:13.)

19. Gbogbo awọn ti emi bá fẹ́ ni mo nbáwí, ti mo si nnà: nitori naa, ni ìtara, ki o si ronúpìwàdà. (Owe 3:11; Heb 12:5:6; Ifh 3:5.)

20. Kiyesi i, mo duro ni ẹnu ilẹkun, mo sì nkànkùn, bi ẹnikẹni bá gbọ ohùn mi, ti o si ṣi ilẹkun, emi o si wọle tọ̀ ọ́ wá, emi o si maa ba a jẹun, ati oun pẹlu mi. (Matt 24:33; Luk 12:36; Jhn 14:23.)

21. Ẹni ti o bá ṣẹgun ni emi o fifun lati jokòó pẹlu mi lori ìtẹ́ mi, bi emi pẹlu ti ṣẹgun, ti mo sì jokòó pẹlu Baba mi lori ìtẹ́ rẹ̀.' (Ifh 2:7; Matt 19:28; Ifh 5:5.)

22. Ẹni ti o bá leti, ki ó gbọ́ ohun ti Ẹmí nsọ fun awọn ìjọ." (Ifh 2:7.)

## ORI 4.

**Awọn ohun ti kò lè ṣaláì ṣẹ: ìjọ́sìn ti ọ̀run.**

LẸHIN nkan wọnyìí emi wo, si kiyesi i, ilẹkun kan ṣí sílẹ̀ ni ọ̀run: ohùn kinni ti mo gbọ bi ohùn ìpè ti nbá mi sọ̀rọ̀, ti o wi pe, "Gòkè wá nihin,

emi ó sì fi ohun ti yoo ṣẹlẹ̀ lẹ́hìn èyí hàn ọ̀." (Ifh 1:10; 11:12; 1:19.)

2. Lojukan naa mo sì wà ninu Ẹmí: si kiyesi i, a tẹ́ ìtẹ́ kan lọ́run ẹnikan si jokòó lori ìtẹ́ naa. (Ifh 1:10; Isa 6:1; Esk 1:26–28; Dan 7:9.)

3. Ẹni ti o si jokòó naa dabi okuta jasperi ati sardiusi ni wíwò: ni àyíká ìtẹ́ naa ni òṣùmàrè kan wà ti o dabi okuta emeradi ni wíwò.

4. Yíká ìtẹ́ naa sì ni ìtẹ́ mẹrinlelogun: ati lori awọn ìtẹ́ naa mo ri awọn àgbà mẹrinlelogun jokòó, ti a wọ̀ ni aṣọ àlà; adé wúrà si wà ni orí wọn. (Ifh 11:16; 3:4:5.)

5. Ati lati ibi ìtẹ́ naa ni ìró mànàmáná ati ohùn ati àárá ti jade wá: niwaju ìtẹ́ naa ni fitila iná meje si ntan èyí ti nṣe Ẹmi meje ti Ọlọrun. (Ifh 8:5; 16:18; 1:4; Sek 4:2.)

6. Ati lati ibi ìtẹ́ naa ni òkun bi digi wà ti o dabi Kristali: ati yí ìtẹ́ naa ká ní ẹ̀gbẹ́ kọọkan ni ẹ̀dá alàáyè mẹrin ti ó kún fun oju niwaju ati lẹhin wà. (Ifh 15:2; Esk 1:5;Job 37:18.)

7. Ẹdá kinni si dabi kinniun, ẹ̀dá keji si dabi ọmọ malu, ẹ̀dá kẹta si ní oju bi ti eniyan, ẹ̀dá kẹrin si dabi ìdì ti nfò. (Esk 1:10; 10:14.)

8. Awọn ẹ̀dá alàáyè mẹrin naa, ti olukuluku wọn ni iyẹ́ mẹfa, kún fún ojú yika ati ninu: wọn kò sì sinmi lọsan ati loru, lati wi pe, "Mímọ́ Mímọ́, Mímọ́, Oluwa Ọlọrun Olodumare, ti o ti wà, ti o si nbẹ, ti o si nbọ̀ wá!" (Isa 6:2,3; Ifh 1:8,4.)

9. Nigba ti awọn ẹ̀dá alàáyè naa bá sì fi ogo ati ọlá, ati ọpẹ́ fún ẹni ti o jokòó lori ìtẹ́, ti o nbẹ laaye lae ati laelae. (Psm 47:8; Ifh 10:6; 15:7.)

10. Awọn àgbà mẹ́rinlélógún naa yoo sì wólẹ̀ niwaju ẹni ti o jókòó lori ìtẹ́, wọn yoo si tẹ́riba fún ẹni ti nbẹ láàyè lae ati laelae, wọn yoo sì fi adé wọn lélẹ̀ niwaju ìtẹ́ naa, wi pe, (Ifh 5:8,14.)

11. "Oluwa, iwọ ni o yẹ lati gba ògo ati ọlá ati agbara: nitori pe ìwọ ni o dá ohun gbogbo, ati nitori ifẹ inu rẹ ni wọn fi wà ti a sì dá wọn." (Ifh 5:12; Gen 1:1; Ef 3:9; Ifh 10:6.)

## ORI 5.

**Ṣíṣí iwe awọ kíká naa ati bíbu ọlá fun ọdọ-agutan naa.**

MO sì ri ni ọwọ́ ọ̀tún ẹni ti o jokòó lori ìtẹ́ naa, iwe kan ti a kọ ninu ati lẹhin, ti a si fi èdìdí meje dí. (ẹsẹ 7:13; Esk 2:9:10; Isa 29:11; Dan 12:4.)

2. Mo sì rí angẹli alagbara kan, o nfi ohùn rara kéde pé, "Tani o yẹ lati ṣí ìwé naa, ati lati tu èdìdí rẹ̀?" (Ifh 10:1.)

3. Kò sì sí ẹni kan ni ọ̀run, tabi lori ilẹ̀ ayé, tabi nisalẹ̀ ilẹ̀, ti o le ṣi iwe naa, tabi ti o lè wo inu rẹ̀.

4. Emi si sọkún gidigidi, nitori ti a kò ri ẹnikan ti o yẹ lati ṣi ati lati ka iwe naa, tabi lati wo inu rẹ̀.

5. Ọkan ninu awọn àgbà naa si wi fun mi pe, "Máṣe sọkún: kiyesi i, kinniun ẹ̀yà Juda, Gbòngbò Dafidi, ti bori lati ṣí iwe naa, ati lati tú èdìdí rẹ̀ mejeeje." (Gen 49:9; Heb 7:14; Isa 11:1:10; Rom 15:12; Ifh 22:16.)

6. Mo sì rí ni aarin ìtẹ́ naa, ati awọn ẹ̀dá alàáyè mẹrin naa, ati ni aarin awọn àgbà naa, Ọdọ-Agutan kan duro bí eyi ti a ti pa, o ni ìwo meje ati ojú meje, ti o jẹ Ẹmi meje ti Ọlọrun, ti a rán jade lọ si orí ilẹ ayé gbogbo. (Ifh 4:6; Isa 53:71; Ifh 13:8; Sek 3:9; 4:10; Ifh 4:5.)

7. O sì wá, o sì gbaa ni ọwọ́ ọ̀tún ẹni ti o jokòó lori ìtẹ́ naa. (ẹsẹ 1.)

8. Nigba ti o si gba ìwé naa, awọn ẹ̀dá alàáyè mẹrin naa, ati awọn àgbà mẹrinlelogun naa wólẹ̀ niwaju Ọdọ-Agùtàn naa, olukuluku wọn mú harpu kan lọwọ, ati ago wúrà ti o kún fún turari ti i ṣe adura awọn eniyan-mímọ́. (Ifh 14:2;Psm 141:2.1Pet3:22.)

9. Wọn si nkọ orin titun kan, wi pe, "Iwọ ni o yẹ lati gba ìwé naa, ati lati ṣi èdìdí rẹ̀: nitori ti a ti pa ọ, iwọ si ti fi ẹ̀jẹ̀ rẹ ṣe irapada eniyan si Ọlọrun lati inu ẹ̀yà gbogbo, ati èdè gbogbo,

ati inu eniyan gbogbo, ati orilẹ-èdè gbogbo wá: (Psm 40:3; Ifh 4:11; 1 Kor 6:20; Heb 9:12.)

10. Iwọ si ti ṣe wọ́n ni ọba ati alufa si Ọlọrun wa: wọn si njọba lori ilẹ ayé." (Eks 19:6; Isa 61:6.)

11. Emi si wo, mo si gbọ ohùn awọn angẹli pupọ yí ìté naa ká, ati yí awọn ẹ̀dá alàáyè naa ati awọn àgbà naa ká: iye wọn si jẹ ẹgbaarun ọna ẹgbaarun ati ẹgbẹẹgbẹ̀rún ọ̀nà ẹgbẹẹgbẹ̀rún. (Dan 7:10; Heb 12:22.)

12. Wọn nwi lóhùn rara pe, "Yiyẹ ni Ọdọ-Agutan naa ti a ti pa, lati gba agbara, ati ọrọ̀ ati ọgbọ́n, ati ipá, ati ọlá, ati ògo, ati ibukun." (Ifh 4:11.)

13. Gbogbo ẹ̀dá ti o si nbẹ ni ọ̀run, ati lori ilẹ ayé, ati nisalẹ ilẹ ati irú awọn ti nbẹ ninu òkun, ati gbogbo awọn ti nbẹ ninu wọn, ni mo gbọ ti nwi pe, "Ki a fi ibukun ati ọlá, ati ògo, ati agbara, fun Ẹni ti o jókòó lori ìté ati fun Ọdọ-Agutan naa lae ati laelae." (Filp 2:10; ẹsẹ 3; 1 Tim 6:16; Ifh 1:6; 6:16; 7:10.)

14. Awọn ẹ̀dá alàáyè mẹrin naa wi pe; "Amin!" Awọn agba mẹrinlelogun naa wólẹ̀, wọn si foribalẹ fun ẹni ti nbẹ láàyè lae ati laelae. (Ifh 19:4; 4:9,10.)

## ORI 6.

**Èdìdí ekinni: ẹṣin funfun kan.**

EMI sì rí nigba ti Ọdọ-Agutan naa ṣí ọkan ninu èdídí wọnyìí, mo si gbọ ọ̀kan ninu awọn ẹ̀dá alàáyè mẹrin naa nwi bi ẹni pe sísán àárá pé, "Wa, wò ó!" (Ifh 5:5–7;14:2;19:6.)

2. Mo si wo, si kiyesi i, ẹṣin funfun kan: ẹni ti o si jokòó lori rẹ̀ ní ọrun kan; a si fi adé kan fun un: o si jade lọ lati ìṣẹ́gun dé ìṣẹ́gun. (Sek 6:3; Ifh 19:11; Sek 6:11; Ifh 14:14.)

**Èdìdí keji: ẹṣin pupa kan.**

3. Nigba ti ó sì ṣí èdídí keji, mo gbọ́ ohùn ẹ̀dá alàáyè keji nwi pé, "Wa, wò ó!" (Ifh 4:7.)

4. Ẹṣin miran ti o pupa sì jáde: a sì fi agbara fun ẹni ti o jókòó lori rẹ̀, lati gba alaafia kuro lori ilẹ̀ ayé ati pé ki wọn maa pa ara wọn: a si fi idà nlá kan le e lọ́wọ́. (Sek 6:2.)

**Èdìdí kẹta; ẹṣin dudu kan.**

5. Nigba ti o si ṣí èdìdí kẹta, mo gbọ ohùn ẹ̀dá alàáyè kẹta nwi pe, "Wa, wò ó!" Mo si wo, si kiyesi i, ẹṣin dúdú kan; ẹni ti o jokòó lori rẹ̀ ni iwọ̀n kan aláwẹ́ meji ni ọwọ́ rẹ̀. (Ifh 4:7; Sek 6:2)

6. Mo si gbọ bi ẹni pe ohùn kan ni àarín awọn ẹ̀dá alàáyè mẹrẹẹrin naa ti nwi pe, "Òṣùwọ̀n alikama kan fun owó idẹ kan, ati òṣùwọ̀n ọka barle mẹta fun owó idẹ kan; ṣùgbọn ki o má si ṣe pa òroró ati ọtí waini lara." (Ifh 4:6,7; 9:5.)

**Èdìdí kẹrin: ẹṣin rándanràndan kan.**

7. Nigba ti o sì ṣí èdìdí kẹrin, mo gbọ́ ohùn ẹ̀dá alàáyè kẹrin nwi pe, "Wa wò ó!" (Ifh 4:7.)

8. Mo sì wo o, si kiyesi i, ẹṣin rán-dan-ràndan kan: orukọ ẹni ti o jokòó lori rẹ̀ ni ikú, ati Isà-òkú sì tọ̀ ọ́ lẹ́hìn. A sì fi agbara fún wọn lori ìdámẹ́rin ayé lati pa pẹlu idà, ati ìyàn, ati àjàkálẹ̀ àrùn, ati ẹranko ori ilẹ̀ ayé pa. (Sek 6:3; Hos 13:14; Esk 5:12.)

**Èdìdí karun: awọn ti a pa nitori ọ̀rọ̀ Ọlọrun.**

9. Nigba ti o si ṣi èdìdí karun, mo ri lábẹ́ pẹpẹ, ọkàn awọn ti a ti pa nitori ọ̀rọ̀ Ọlọrun, ati nitori ẹ̀rí ti wọn dìmú: (Ifh 14:18; Hos 13:14.)

10. Wọn kigbe ni ohùn rara, wi pe, "Yoo ti pẹ tó, Oluwa, Ẹni mímọ́ ati olootọ, ti iwọ yoo fi ṣe idajọ ati lati gbẹ̀san ẹ̀jẹ̀ wa lórí awọn ti ngbe ori ilẹ ayé?" (Sek 1:12; Psm 79:5; Ifh 3:7; 19:2.)

11. A si fi aṣọ funfun fun gbogbo wọn; a si wi fun wọn pe, ki wọn o sinmi di ìgbà diẹ naa, titi iye awọn iranṣẹ ẹlẹ́gbẹ́ ati arakunrin wọn ti a o pa bi ti wọn, yoo fi pé. (Ifh 3:5; 7:9; 14:13; Heb 11:40.)

**Èdìdí kẹfa: awọn àmìn ni ọ̀run.**

12. Nigba ti o si ṣi èdìdí kẹfa mo sì rí, ìmìmì-ilẹ̀ nlá kan si mi ; òòrùn si

dúdú bi aṣọ ọ̀fọ̀ onírun, oṣupa si dabi ẹ̀jẹ̀; (Ifh 16:18; Matt 24:29; Joel 2:31; A.A. 2:20.)

13. Awọn iràwọ̀ oju ọrun si ṣubu silẹ̀ gẹgẹ bi igi ọ̀pọ̀tọ́ ti ṣe nrẹ àìgbó èso rẹ̀ dànù nigba ti ẹ̀fúùfù nlá bá mì ín (Ifh 8:10; 9:1; Isa 34:4.)

14. A si ká ọrun kuro bí ìwé ti a ká; ati olukuluku òkè ati erékùṣù ni a si ṣí kuro ni ipo wọn. (Isa 34:4; Jer 3:23; 4:24; Ifh 16:10.)

15. Awọn ọba ayé ati awọn ọlọ́lá ati awọn olori ogun, ati awọn ọlọ́rọ̀, ati awọn alagbara, ati olukuluku ẹrú, ati olukuluku ominira si fi ara wọn pamọ́ ninu ihò- ilẹ̀, ati ninu àpáta orí òkè; (Isa 2:10:19.)

16. Wọn si nwi fun awọn òkè ati awọn àpáta naa pe, "Ẹ wólù wá, ki ẹ si fi wá pamọ́ kúrò loju ẹni ti o jokòó lori ìtẹ́, ati kuro ninu ibinu Ọdọ́-Agutan naa: (Hos 10:8; Luk 23:30; Ifh 9:6.)

17. Nitori ọjọ nla ibinu wọn dé; tani sì lè dúró?!" (Sef 1:14; Ifh 16:14; Psm 75:1.)

## ORI 7.

**Fífi èdìdí sàmì si iwaju-ori awọn iranṣẹ Ọlọrun.**

LẸHIN eyi ni mo ri angẹli mẹrin duro ni igun mẹrẹrin ayé, wọn di afẹfẹ mẹrẹrin ayé mu, ki o máṣe fẹ́ sori ilẹ̀, tabi sori òkun, tabi sara igikígi. (Ifh 9:4.)

2. Mo sì rí angẹli miran ti o nti iha ila-oorun gòkè wá, pẹlu èdídí Ọlọrun alààyè lọ́wọ́; o si kigbe lóhùn rara si awọn angẹli mẹrin naa ti a fifun lati pa ayé ati òkun lara.

3. Wi pe,"E máṣe pa ayé tabi òkun tabi igi lara, titi a o fi fi èdìdì sàmì si awọn iranṣẹ Ọlọrun wa ni iwájú ori wọn!" (Ifh 6:6; Esk 9:4; Ifh 22:4.)

4. Mo si gbọ iye awọn ẹni ti a fi èdìdí sàmì si: awọn ti a sàmì si jẹ ọkẹ́ meje o lé ẹgbaajì lati inu gbogbo ẹ̀yà awọn ọmọ Israẹli wá. (Ifh 9:16; 14:1.)

5. Lati inu ẹ̀yà Juda a fi èdìdí sàmì si ẹgbaa mẹfa. Lati inu ẹ̀yà Reubẹni a fi èdìdí sàmì si ẹgbaa mẹfa. Lati inú ẹ̀yà Gadi a fi èdídí sàmì si ẹgbaa mẹfa.

6. Lati inu ẹ̀yà Aseri a fi èdídí sàmì si ẹgbaa mẹfa. Lati inu ẹ̀yà Neftalimu a fi èdìdí sàmì si ẹgbaa mẹfa. Lati inu ẹ̀yà Manasse a fi èdìdí sàmì si ẹgbaa mẹfa.

7. Lati inu ẹ̀yà Simeoni a fi èdìdí sàmì si ẹgbaa mẹfa. Lati inú ẹ̀yà Lefi a fi èdìdí sàmì si ẹgbaa mẹfa. Lati inu ẹ̀yà Issakari a fi èdìdí sàmì si ẹgbaa mẹfa.

8. Lati inu ẹ̀yà Sebuluni a fi èdìdí sàmì si ẹgbaa mẹfa. Lati inu ẹ̀yà Josẹfu a fi èdìdí sàmì si ẹgbaa mẹfa. Lati inu ẹ̀yà Bẹnjamini a fi èdìdí sàmì si ẹgbaa mẹfa.

**Awọn ìjọ ènìyàn-mimọ ti o jade lati inú ìpọnju nlá ti a wọ̀ ni aṣọ funfun.**

9. Lẹ́hìn naa, mo ri, si kiyesi i, ọ̀pọ̀lọpọ̀ eniyan ti ẹnikẹni kò lè kà, lati inu orilẹ-èdè gbogbo, ati ẹ̀yà, ati eniyan, ati lati inu èdè gbogbo wá, wọn duro niwaju ìtẹ́, ati niwaju Ọdọ́-Agutan naa, a wọ̀ wọ́n ni aṣọ funfun, imọ̀ ọ̀pẹ si nbẹ ni ọwọ́ wọn; (Rom 11:25; Ifh 5:9; 3:5,18; 4:4; 6:11.)

10. Wọn si kigbe ni ohùnrara, wí pé, "Igbala ni ti Ọlọrun wa ti o joko lori ìtẹ́, ati ti Ọdọ́-Agutan!" (Psm 3:8; Ifh 12:10; 19:1; 5:13.)

11. Gbogbo awọn angẹli si duro yí ìtẹ́ naa ká, ati yi awọn àgbà ati awọn ẹ̀dá alààyè mẹrin naa ká, wọn wólẹ̀ wọn si dojubolẹ̀ niwaju ìtẹ́ naa wọn si sin Ọlọrun. (Ifh 4:6.)

12. Wi pe, "Amin: Ibukun, ati ògo, ati ọgbọ́n, ati ọpẹ́, ati ọlá, ati agbara ati ipá fun Ọlọrun wa lae ati laelae! Amin." (Ifh 5:12–14.)

13. Ọkan ninu awọn àgbà naa si dáhùn, o bi mi pé, "Tani awọn wọnyìí ti a wọ ni aṣọ funfun? nibo ni wọn sì ti wá?" (ẹsẹ 9.)

14. Mo si wi fun un pé, "Oluwa mi, Iwọ ni o lè mọ̀." O si wi fun mi pé, "Awọn wọnyìí ni o jade lati inú ipọnju nla, wọn si fọ aṣọ wọn wọn si sọ wọn di

funfun ninu Ẹ̀jẹ̀ Ọdọ-Agutan naa. (Matt 24:21; Sek 3:3–5; Heb 9:14; 1 Jhn 1:7.)

15. Nitori naa ni wọn ṣe nbẹ niwaju ìtẹ́ Ọlọrun, ti wọn si nsin in, lọ́sàn ati loru ninu tẹmpili rẹ̀: ẹni ti o jokòó lori ìtẹ́ naa yoo si ṣiji bò wọn. (Isa 4:5,6; Ifh 21:3.)

16. Ebi ki yoo pa wọn mọ́, bẹẹ ni oungbẹ ki yoo gbẹ wọ́n mọ́; bẹẹ ni òòrùn ki yoo pa wọn tabi oorukóoru kan. (Isa 49:10; Psm 121:5,6; Ifh 21:4.)

17. Nitori Ọdọ-Agutan ti nbẹ ni aarin ìtẹ́ naa ni yoo maa ṣeOluṣọ-Agutan wọn, ti yoo si maa ṣe amọ̀nà wọn si ibi orisun omi ìyè: Ọlọrun yoo si nu omijé gbogbo nù kuro ni ojù wọn." (Psm 23:1; Jhn 10:11,14; Isa 25:8.)

## ORI 8.

**Èdìdí keje: pípèsè awọn ìpè silẹ.**

NIGBA ti o si ṣí èdìdí keje, idakẹ rọ́rọ́ sì wà ní ọ̀run níwọ̀n ààbọ̀ wakati kan. (Ifh 6:1.)

2. Mo sì rí awọn angẹli meje ti wọn dúró niwaju Ọlọrun; a si fi ìpè meje fun wọn. (1 Kor 15:52; 1 Tess 4:16.)

3. Angẹli miran si wá, o si duro ti pẹpẹ, o ni àwo turari wura kan a sì fi turari pupọ fun un, lati maa fi kún adura gbogbo awọn eniyan mímọ́ lori pẹpẹ wura ti nbẹ niwaju ìtẹ́. (Ifh 7:2; 5:8; Eks 30:1; Ifh 6:9.)

4. Ati eefin turari naa pẹlu adura awọn eniyan-mímọ́ sì goke lọ siwaju Ọlọrun lati ọwọ́ angẹli naa wa. (Psm 141:2.)

5. Angẹli naa si mu àwo turati naa, o si fi ina ori pẹpẹ kún un, o si dà á sori ilẹ ayé: a sì gbọ́ ohùn, àárá sì sán, mànàmáná si kọ, ìmìmì-ilẹ̀ sì mì. (Lef 16:12; Ifh 4:5; 6:12.)

6. Awọn angẹli meje naa ti wọn ni ìpè meje sì mura lati fun wọn. (ẹsẹ 2.)

**Ìpè ekinni: yìnyín, iná, ati ẹ̀jẹ̀.**

7. Ekinni si fun ìpè tirè: yìnyín ati iná, ti o dàpọ̀ pẹlu ẹ̀jẹ̀, si jade, a si dà wọ́n sori ilẹ ayé: idamẹta ilẹ̀ ayé si jóná, idamẹta awọn igi si jóná, ati gbogbo koríko tútù si jóná. (Esk 38:22; Ifh 9:4.)

**Ìpè keji: òkun di ẹ̀jẹ̀.**

8. Angẹli keji si fun ìpè tirẹ̀, a sì sọ ohun kan, bi oke-nla ti njóná, sinu òkun: idamẹta òkun si di ẹ̀jẹ̀; (Jer 51:25; Ifh 16:3.)

9. Ati idamẹta awọn ẹ̀dá ti nbẹ ninu òkun ti o ni ẹ̀mí si kú; ati idamẹta awọn ọkọ̀ si bàjẹ́.

**Ìpè kẹta: ìràwọ̀ ti o njó bi fìtílà.**

10. Angẹli kẹta si fun ìpè tirẹ̀, ìràwọ̀ nlá kan ti njo bi fitílà si bọ lati ọrun wá, o si bọ sori idamẹta awọn odò ṣíṣàn, ati sori awọn orisun omi; (Ifh 16:4–7.)

11. A si npe orukọ ìràwọ̀ naa ni Iwọ, idamẹta awọn omi si di iwọ, ọpọlọpọ eniyan si ti ipa awọn omi naa kú, nitori ti a sọ wọn di kikorò. (Jer 9:15; 23:15.)

**Ìpè kẹrin: òòrùn, ọ̀ṣùpá, ati ìràwọ̀ ṣókùnkùn.**

12. Angẹli kẹrin si fun ìpè tirẹ̀, a si kọlu idamẹta òòrùn, ati idamẹta oṣupa, ati idamẹta awọn ìràwọ̀, ki idamẹta wọn lè ṣóòkùn, kí ọjọ́ máṣe mọ́lẹ̀ fun idamẹta rẹ̀, ati òru bakannaa. (Ifh 6:12,13; 16:8,9.)

13. Mo sì wò, mo si gbọ idì kan ti nfò ni aarin ọrun, o nwi lóhùn rara pé "Ègbé, ègbé ègbé, fun awọn ti ngbe ori ilẹ̀ ayé nitori ohun ìpè iyoku ti awọn angẹli mẹta ti nbọ̀ wá yoo fun!" (Ifh 14:6; 19:17; 9:12; 11:14.)

## ORI 9.

**Ìpè karun: ṣíṣí ọ̀gbun àìnísàlẹ̀.**

ANGẸLI karun si fun ìpè tirẹ̀ mo si ri ìràwọ̀ kan bọ́ silẹ̀ lati ọrun wá: a sì fi kọ́kọ́rọ́ ihò ọ̀gbun fun un. (Ifh 8:10; Luk 8:31; Ifh 16:10–11.)

2. O si ṣi ihò ọ̀gbun naa, èéfín si rú jade lati inú ihò naa wá, bi èéfín ileru nla; òòrùn ati ojú sanma si ṣòòkùn nitori eefin ihò naa. (Gen 19:28; Eks 19:18; Joel 2:2,10.)

3. Awọn eeṣú si jade ti inu eefin naa

wa sori ilẹ: a si fi agbara fun wọn gẹgẹ bi agbara àkéekèe ilẹ̀. (Eks 10:12–15; ẹsẹ 10.)

4. A si sọ fun wọn pé ki wọn má ṣe pa koriko ilẹ̀ lara, tabi ohun tútù kan, tabi igikigi kan; bikoṣe awọn eniyan ti kò ni èdìdí Ọlọrun ni iwaju wọn. (Ifh 6:6; 16:10–11; 7:2,3.)

5. A si pàṣẹ fun wọn pé, ki wọn má ṣe pa wọ́n, ṣugbọn ki a dá wọn ni oró ni oṣu marun: oró wọn si dabi oró àkéekèe, nigba ti o bá ta ènìyàn. (ẹsẹ 10:3.)

6. Ni ọjọ wọnyìí ni awọn eniyan yoo si maa wá ikú, wọn ki yoo si ri i; wọn o si fẹ́ lati kú, ikú yoo si sa kuro lọ́dọ̀ wọn. (Job 3:21; Jer 8:3; Ifh 6:16.)

7. Ìrísí awọn eeṣú naa si dàbí awọn ẹṣin ti a mura silẹ fun ogun; ati ni orí wọn ni ohun ti o dàbí awọn adé wura wà, oju wọn si dabi ojú ènìyàn; (Joel 2:4; Nah 3:17; Dan 7:8.)

8. Wọn si ni irun bi obinrin, ehín wọn si dabi ti kinniun. (Joel 1:6).

9. Wọn si ni ìgbàyà ti o dabi ìgbàyà irin; ìró ìyẹ́ wọn si dabi ìró kẹ̀kẹ́ ẹṣin pupọ ti nsúré lọ si ogun. (Joel 2:5.)

10. Wọn si ni ìrù ati oró bi ti àkéekèe, ati ni ìrù wọn ni agbara wọn wà lati pa eniyan lara fun oṣù marun. (ẹsẹ 5:19.)

11. Wọn ni angẹli ọ̀gbun naa bi ọba lori wọn, orúkọ rẹ̀ ni èdè Heberu ni Abaddoni, ati ni èdè Griki orúkọ rẹ̀ a maa jẹ Apollioni. (Ef 2:2; ẹsẹ 1.)

12. Ègbé kan ti kọja, kiyesi i, ègbé meji nbọ sibẹ lẹhin èyí. (Ifh 8:13.)

**Ìpè kẹfa: Títú awọn angẹli mẹrin silẹ.**

13. Angẹli kẹfa si fun, mo si gbọ ohùn kan lati ibi ìwo mẹrin pẹpẹ wura wá, ti nbẹ niwaju Ọlọrun. (Eks 30:1–3; Ifh 8:3.)

14. Oun wí fún angẹli kẹfa naa ti o ni ìpè naa pé, "Tú awọn angẹli mẹrin naa silẹ ti a dè lẹba odo nla Eufrate!" (Ifh 7:2; 16:12.)

15. A si tú awọn angẹli mẹrin naa silẹ, ti a ti pèsè tẹ́lẹ̀ fún wakati naa, ati ọjọ́ naa, ati ọ̀ṣu naa, ati ọdún naa, lati pa idamẹta ènìyàn. (ẹsẹ 18.)

16. Iye ogun awọn ẹlẹ́ṣin si jẹ aadọta ọ̀kẹ́ lọ́nà igba: mo si gbọ iye wọn. (Ifh 5:11; 7:4.)

17. Bayìí ni mo sì rí awọn ẹṣin naa ni ojúran, ati awọn ti o gùn wọ́n, wọn ni ìgbàyà aláwọ̀ iná, ati ti jakinti, ati ti sulfuru: orí awọn ẹṣin naa si dabi orí awọn kìnnìún; ati lati ẹnu wọn ni iná, ati eefin, ati sulfúrù ti njáde. (ẹsẹ 18; Ifh 11:5;20:7–10;16:12–16.)

18. Nipa ìyọnu mẹta wọnyìí ni a ti pa idamẹta eniyan, nipa iná, ati nipa eefin, ati nipa sulfuru ti o nti ẹnu wọn jade. (ẹsẹ 15,17.)

19. Nitori pé agbara awọn ẹṣin naa nbẹ ni ẹnu wọn ati ni ìrù wọn: nitori pe ìrù wọn dabi ejò, wọn si ni orí, awọn wọ̀nyìí ni wọn si fi npani lara.

20. Ṣugbọn awọn eniyan iyoku ti a kò sì ti ipa ìyọnu wọnyìí pa, kò si ronupiwada iṣẹ́ ọwọ́ wọn, ki wọn má ṣe sin awọn ẹ̀mí-èṣù, ati ère wúrà, ati ti fàdákà, ati ti idẹ, ati òkúta, ati ti igi mọ́: awọn ti kò lè riran, tabi ki wọn gbọ́ràn, tabi ki wọn rìn: (Deut 31:29; 1 Kor 10:20; Psm 115:4; 135:15; Dan 5:23.)

21. Bẹẹ ni wọn kò ronupiwada iwa ipaniyan wọn, tabi oṣó wọn tabi àgbèrè wọn, tabi olè wọn. (Ifh 2:21; 18:23; 17:2,5.)

## ORI 10.

**Johanu jẹ ìwé kekere naa.**

MO sì ri angẹli miran alágbara o nti ọ̀run sọkalẹ wá, a fi awọsánma wọ̀ ọ́ ni aṣọ: òṣùmàrè si nbẹ ni orí rẹ̀, ojú rẹ̀ si dabi òòrùn, ati ẹsẹ̀ rẹ̀ bi ọ̀wọ̀n iná: (Ifh 5:2; Matt 17:2; Ifh 1:15,16.)

2. O si ni iwe kekere kan ti a ṣi ni ọwọ́ rẹ̀: o si fi ẹsẹ̀ rẹ̀ ọ̀tún lé òkun, ati ẹsẹ rẹ̀ òsì lé ilẹ̀.

3. O si ké lohùn rara, bí ìgbà tí kinniun bá bú ramúramù: nigba ti o si ké, awọn àárá meje naa fọhùn. (Isa 31:4; Ifh 4:5.)

4. Nigba ti awọn àará meje fọhùn, mo mura ati kọ̀wé: mo si gbọ ohùn lati ọ̀run wá nwi fun mi pé, "Fi èdìdí di ohun ti awọn àará meje naa sọ, má si ṣe kọ wọn sílẹ̀." (Dan 8:26; 12:4,9; Ifh 22:10.)

5. Angẹli naa ti mo rí ti o duro lori òkun ati lori ilẹ̀, si gbe ọwọ́ rẹ̀ si òkè ọ̀run: (Eks 6:8; Dan 12:7.)

6. O si fi ẹni ti nbẹ láàyè lae ati lae-lae bura, ẹni ti o dá ọ̀run, ati ohun ti nbẹ ninu rẹ̀, pé: ki a má ṣe jáfara mọ́. (Ifh 4:11; 14:7; 16:17.)

7. Ṣugbọn ni ọjọ ohùn ìpè angẹli keje, nigba ti yoo ba fun ìpè, nigba naa ni ohun ìjìnlẹ̀ Ọlọrun, gẹ́gẹ́ bí o ti sọ fún awọn iranṣẹ rẹ̀, awọn woli ni a o mú ṣẹ. (Ifh 11:15; Rom 16:25; Dan 12:2; Ifh 20:11–15.)

8. Ohùn naa ti mo gbọ́ lati ọ̀run tun nba mi sọ̀rọ̀, ó si wi pé, "Lọ, gba ìwé tí a ṣí náà lọwọ angẹli ti o duro lori òkun ati lori ilẹ̀." (ẹsẹ 4.)

9. Mo si tọ angẹli naa lọ, mo si wi fun un pe,"Fun mi ni ìwé kekere naa." O si wi fun mi pé, "Gbà ki o si jẹ ẹ tán: yoo mú inú rẹ korò, ṣugbọn ní ẹnu rẹ yoo dabi oyin." (Jer 15:16; Esk 2:8.)

10. Mo si gba ìwé kekere naa ni ọwọ́ angẹli naa mo si jẹ ẹ tán ; o si dùn lẹnu mi bi oyin: bi mo si ti jẹ ẹ tán, inu mi korò. (Esk 3:3.)

11. A si wi fun mi pé, "Iwọ o si tun sọ asọtẹlẹ nipa ọpọlọpọ eniyan, ati orilẹ ati èdè, ati awọn ọba." (Ifh 11:1.)

## ORI 11.

**Ẹlẹri Ọlọrun meji (asọtẹlẹ̀ awọn eni-yan Ọlọrun naa ori 10:11).**

A sì fi ìféèfé kan fun mi ti o dabi ọ̀pá: ẹnikan si wi pe, "Dide, wọn tẹmpili Ọlọrun, ati pẹpẹ, ati awọn ti nsìn ninu rẹ̀. (Esk 40:3; Ifh 21:15.)

2. Si fi àgbàlá ti nbẹ lóde tẹmpili silẹ, má si ṣe wọ̀n ọ́n; nitori tí a fi i fun awọn Keferi: ìlú mímọ́ naa ni wọn o sì tẹ̀ mọ́lẹ̀ ni oṣù meji lé logoji. (Esk 40:17; Luk 21:24; Ifh 13:5.)

3. Emi o si yọ̀nda fun awọn ẹlẹri mi méjèjì, wọn o si sọtẹ́lẹ̀ fun ẹgbẹfa ọjọ o-le-ọgọta ninu aṣọ-ọ̀fọ̀." (Ifh 19:10; 12:6.)

4. Wọnyìí ni igi olifi meji naa, ati ọ̀pá fitila meji naa tí nduro niwaju Oluwa ayé. (Psm 52:8; Jer 11:16; Sek 4:3:11:14;Rom 11:17; Ifh 1:20.)

5. Bi ẹnikẹni bá sì fẹ́ pa wọn lara, iná o ti ẹnu wọn jade, a si pa awọn ọ̀tá wọn run: bayìí ni a o si pa ẹnikẹni ti ó ba nfẹ́ pa wọn lara run. (2 A.Ọba 1:10; Jer 5:14; Num 16:29.)

6. Awọn wọnyìí ni o ni agbara lati sé ọ̀run, ti òjò kò fi lè rọ̀ ni ọjọ́ asọtẹlẹ wọn: wọn si ni agbara lori omi lati sọ wọn di ẹ̀jẹ̀, ati lati fi oniruuru ajakalẹ àrùn kọlu ayé, nigbakugba ti wọn bá fẹ́. (1 A.Ọba 17:1; Eks 7:17,19.)

7. Nigba ti wọn bá sì ti pari ẹ̀rí wọn, ẹranko ti o nti inu ọ̀gbun goke wa yoo ba wọn jagun, yoo si ṣẹgun wọn, yoo si pa wọn. (Ifh 13:1; 9:1,2; Dan 7:21.)

8. Okú wọn yoo si wà ni igboro ilu nla naa, ti a npe ni Sodomu ati Egipti nipa ti ẹ̀mí, nibi ti a gbe kan 'Oluwa wọn mọ agbelebu. (Ifh 14:8; Isa 1:9; Heb 13:12.)

9. Fun ijọ́ mẹta ati ààbọ̀ ni awọn eniyan ninu eniyan gbogbo ati ẹ̀yà, ati èdè, ati orilẹ, wo òkú wọn, wọn kò si jẹ ki a gbe òkú wọn sinu iboji.

10. Ati awọn ti o ngbe ori ilẹ̀ ayé yoo si yọ̀ lé wọn lori, wọn yoo si ṣe ariya, wọn o si ta ara wọn lọ́rẹ; nitori tí awọn woli mejeeji yìí dá awọn ti o nbẹ lori ilẹ̀ ayé lóró, (Ifh 3:10; Est 9:19,22.)

11. Ati lẹ́hìn ijọ́ mẹta ati ààbọ̀ naa, ẹ̀mí iyè lati ọ̀dọ̀ Ọlọrun wá wọ inú wọn, wọn si dide dúró ni ẹsẹ̀ wọn; ẹ̀rù nla si ba awọn ti o ri wọn. (Esk 37:5; 9:10,14.)

12. Wọn si gbọ ohùn nla kan lati ọ̀run wa nwi fun wọn pé, "Ẹ goke wá ìhín!" Wọn si goke lọ si ọ̀run ninu ikuukuu awọsanma; loju awọn ọ̀tá wọn. (Ifh 4:1; 2 A.Ọba 2:11; A.A. 1:9.)

13. Ni wakati naa ìmìmì-ilẹ̀ nlá kan
sì mi, idamẹwa ìlú naa sì wó, ati ninu
ìmimi-ilẹ̀ naa ẹẹdẹgbaarin eniyan ni a
pa: ẹ̀rù si ba awọn iyoku,wọn si fi ogo
fun Ọlọrun ọ̀run.(Ifh 6:12;14:7;16:11
14. Ègbé keji kọja; si kiyesi i, ègbé
kẹta si nbọ̀ wá kánkán. (Ifh 9:12.)

**Ipe keje: Jesu jọba, o si ṣe idajọ́.**

15. Angẹli keje si fun ìpè; a si gbọ́
ohùn nlá lati ọ̀run, wi pe, "Ijọba ayé di
ti Oluwa wa, ati ti Kristi rẹ̀; oun yoo sì
jọba lae ati laelae!" (Ifh 10:7,16,17;
19:1; 12:10; Dan 2:44; 7:14,27.)
16. Awọn àgbà mẹrinlelogun naa ti
wọn jókòó niwaju Ọlọrun lori ìtẹ́ wọn,
dojubolẹ̀, wọn sì sìn Ọlọrun. (Ifh 4:4;
5:8.)
17. Wi pe, "Awa fi ọpẹ́ fun ọ, Olu-
wa Ọlọrun, Olodumarè, ti nbẹ, ti o
sì tì wà, nitori pe iwọ ti gba agbara nla
rẹ, iwọ sì ti jọba. (Ifh 1:8; 19:6.)
18. Inu bi awọn orilẹ-èdè, ṣugbọn
ibinu rẹ sì dé, ati àkókò lati dá awọn
òku lẹ́jọ́, ati lati fi èrè fun awọn iranṣẹ
rẹ, woli, ati awọn eniyan mímọ́, ati
awọn ti o bẹ̀rù orukọ rẹ, ati ẹni kéke-
ré ati ẹni nla; ati lati run awọn ti npa
ayé run." (Psm 2:1; Dan 7:9,10; Ifh
10:7; 19:5,6.)
19. A sì ṣí tẹmpili Ọlọrun silẹ̀ ni
ọ̀run, a si rí apoti majẹmu ninu tẹmpili
rẹ̀: mànàmáná si kọ, a si gbọ́ ohùn,
àárá sì sán, ìmimi-ilẹ̀ sì mi, yìnyín nla si
bọ́.(Ifh 15:5,8; 8:5; 16:21.)

ORI 12.

**Obinrin ti o lóyún, ti o si nrọbí (Isra-ẹli).**

AMI nla kan si hàn ni ọ̀run; obinrin
kan ti a fi òòrùn wọ̀ ni aṣọ, oṣupa
si nbẹ lábẹ́ ẹsẹ̀ rẹ̀, adé oníràwọ̀ mejila
si nbẹ lori rẹ̀:

**Dragoni pupa nla kan (Eṣu).**

2. O si lóyun, o si kigbe ni ìrọbí, o si
wà ni ìrora ati bímọ. (Isa 66:7; Gal
4:19.)
3. Àmì miran si hàn lọ́run; si kiyesi
i, *dragoni pupa nlá kan, ti o ni orí
meje ati ìwo mẹwa, ati ade meje ni ori
rẹ̀. (Ifh 13:1; Dan 7:7; Ifh 19:12.)
4. Ìrù rẹ̀ si wọ́ ìdá mẹta awọn ìràwọ̀,
o si jù wọn si ilẹ̀ ayé, dragoni naa si
duro niwaju obinrin naa ti o fẹ bímọ,
pé nigba ti o bá bii, ki oun lè pa ọmọ rẹ̀
jẹ. (Ifh 8:7,12; Dan 8:10.)

**Ọmọkunrin kan ti obinrin naa bí (Kri-sti).**

5. O si bi ọmọkunrin kan ti yoo fi
ọ̀pá irin ṣe àkóso gbogbo awọn orilẹ-
èdè: a si gba ọmọ rẹ̀ lọ sókè sí ọdọ
Ọlọrun, ati si orí ìtẹ́ rẹ̀. (Psm 2:9; Ifh
2:27; Psm 110:1–7.)
6. Obinrin naa si sá lọ si aginjù, nibi
ti a gbe ti pèsè àyè sílẹ̀ dèé lati ọwọ́
Ọlọrun wá, pé ki wọn maa bọ ọ nibẹ ni
ẹgbẹfa ọjọ́ o-le-ọgọta. (Ifh 11:3.)

**Mikaẹli ati awọn angẹli rẹ̀ (Ogun Ọrun).**

7. Ogun si nbẹ ni ọrún: Mikaẹli ati
awọn angẹli rẹ̀ bá dragoni naa jagun;
dragoni si jagun ati awọn angẹli rẹ̀.
(Dan 10:13; Ifh 20:2.)
8. Wọn kò si le ṣẹgun; Bẹẹ ni a kò sì
ri ipò wọn mọ́ ni ọ̀run.
9. A si le dragoni nla naa jade, ejò
laelae ni, ti a npe ni Èṣù, ati Satani, ti
ntan gbogbo ayé jẹ: a si le e jù sí ilẹ̀
ayé, a si le awọn angẹli rẹ̀ jade pẹlu rẹ̀.
(Gen 3:1,4; Ifh 20:2; 3:8,10; Jhn
12:31.)
10. Mo si gbọ ohùn rara ni ọ̀run, nwi
pè, "Nigba yií ni igbàlà de, ati agbara,
ati ijọba Ọlọrun wa, ati ọlá ati Kristi
rẹ̀; nitori a ti le olùfisùn awọn arakun-
rin wa jade, ti o nfi wọn sùn niwaju
Ọlọrun wa lọsan ati loru. (Ifh 11:15;
Job 1:9–11; Sek 3:1.)
11. Wọn si ti ṣẹgun rẹ̀ nitori ẹ̀jẹ̀
Ọdọ-Agutan naa, ati nitori ọ̀rọ̀ ẹ̀rí
wọn, wọn kò si fẹran ẹ̀mí wọn àní titi
de ikú. (Rom 16:20; Luk 14:26.)
12. Nitori naa ẹ maa yọ̀, ẹ̀yin ọ̀run,

(3) *"Dragoni" yií dabi ejò nla kan ti o nyọ iná jade lẹ́nu, ti o si bani lẹ́rù. Kii ṣe "ikookò" gẹgẹ bi awọn Bi-beli atijọ miran ti pe e. (Wo Ifh 12:9 – nibi ti ati pe e ni "ejo laelae.")

ati ẹ̀yin ti ngbé inu wọn. Ègbé ni fún ayé ati òkun; nitori Èṣù sọkalẹ tọ̀ yin wá ní ibinu nlá, nitori o mọ pe ìgbà kúkúrú sà ni oun ni." (Psm 96:11; Isa 49:13; Ifh 18:20; 8:13; 10:6.)

13. Nigba ti dragoni naa ri pé a lé oun lọ si ilẹ ayé, o ṣe inunibini si obinrin ti o bi ọmọkunrin naa. (ẹsẹ 3,5.)

14. A si fi apá iyẹ́ meji ti idì nlá naa fun obinrin naa, pe ki o fò lọ si aginju, si ipò rẹ̀, nibi ti a o gbe bọ ọ fun àkókò kan ati fun awọn àkóko, ati fun ìdajì akókò kuro lọdọ ejò naa. (Eks 19:4; Dan 7:25; 12:7.)

15. Ejò naa si tu omi jade lati ẹnu rẹ̀ wa bi odò nla sẹhin obinrin naa ki o le fi ìṣàn omi naa gba a lọ. (Isa 59:19.)

16. Ilẹ̀ si ran obinrin naa lọwọ, ilẹ si ya ẹnu rẹ̀, o si fi ìṣàn omi naa mu, ti dragoni naa tù jade lati ẹnu rẹ̀ wá.

17. Dragoni naa si binu gidigidi si obinrin naa, o si lọ bá awọn irú-ọmọ rẹ̀ iyoku jagun, ti wọn npa ofin Ọlọrun mọ̀, tí wọn si di ẹ̀rí Jesu mu, O si duro lori iyanrin òkun. (Gen 3:15; Ifh 11:7.)

## ORI 13.

**Ẹranko kan ti nti inu òkun jade wá (Aṣòdisí-Kristi).**

MO sì rí ẹranko kan nti inu òkun jade wá, o ni ori meje ati ìwo mẹwa, lori awọn ìwo naa ni orukọ ọ̀rọ̀-odi wà. (Dan 7:1–6; Ifh 17:13.)

2. Ẹranko ti mo ri naa si dabi ẹkùn, ẹsẹ̀ rẹ si dabi ti beari ẹnu rẹ̀ si dabi ti kinniun: dragoni naa si fun un ni agbara rẹ̀, ati ìtẹ́ rẹ̀, ati àṣẹ nla.

3. Mo si ri ọkan ninu awọn orí rẹ̀ bi ẹni pé a ṣa a pa, a si ti wo ọgbẹ́ àṣápa rẹ̀ naa sàn, gbogbo ayé si fi iyanu tẹle ẹranko naa. (Ifh 17:8.)

4. Wọn si foribalẹ̀ fun dragoni naa, nitori ti o fún ẹranko naa ni àṣẹ, wọn si foribalẹ̀ fun ẹranko naa, wi pe, "Tani o dàbí ẹranko yìí? Tani ó sì lè bá a jagun?"

5. A si fun un ni ẹnu lati maa sọ ohun nla ati ọ̀rọ̀-òdì; a si fi agbara fun un lati ṣe bẹẹ ni oṣu mejilelogoji. (Dan 7:8,11,25; Ifh 12:2.)

6. O si ya ẹnu rẹ̀ ni ọ̀rọ̀-òdì sí Ọlọrun, lati sọ ọ̀rọ̀-òdì si orukọ rẹ̀, ati si àgọ́ rẹ̀, ati si awọn ti ngbe ọrun. (Ifh 12:12.)

7. A si fun un lati maa ba awọn eniyan-mímọ́ jagun, ati lati ṣẹgun wọn: a si fi agbara fun un lori gbogbo ẹ̀yà, ati eniyan, ati èdè, ati orílẹ̀. (Dan 7:21; Ifh 11:7; 5:9.)

8. Gbogbo awọn ti ngbe ori ilẹ̀ ayé yoo si maa sìn ín, olukuluku ẹni ti a kò kọ orukọ rẹ̀, sinu iwe-ìyè Ọdọ-Agutan ti a ti pa lati ìpilẹ̀ṣẹ̀ ayé. (Filp 4:3; Ifh 3:5; 17:8; 5:6.)

9. Bi ẹnikẹni bá létí kí o gbọ́. (Mk 4:23; Ifh 2:7.)

10. Ẹni ti a ti pinnu rẹ̀ fun ìgbèkùn, ìgbèkùn ni yoo lọ; ẹni ti a sì ti pinnu rẹ̀ fún idà, ni a ó sì fi idà pa. Níhìn ni sùúrù ati igbagbọ awọn eniyan mímọ́ wà. (Jh 16:2; Ifh 6:9.)

**Ẹranko miran lati inu ilẹ wá (Woli Èke ti Aṣòdisí-Kristi).**

11. Mo si ri ẹranko miran goke lati inu ilẹ wá; o si ni ìwo meji bí ọ̀dọ́-agutan, o si nsọrọ bi dragoni. (Ifh 16:13.)

12. O si nlo gbogbo agbara ẹranko ekinni niwaju rẹ̀, o si mu ilẹ ayé ati awọn ti ngbe inu rẹ̀ foribalẹ fun ẹranko ekinni ti a ti wo ọgbẹ́ àṣápa rẹ̀ sàn. (ẹsẹ 4,14; Ifh 14:9,11; ẹsẹ 3.)

13. O si nṣe ohun iyanu nla, àní ti o fi nmu iná sọkalẹ lati ọrun wá si ilẹ̀ ayé niwaju awọn eniyan. (Matt 24:24; Ifh 16:14; 1 A.Ọba 20:9.)

14. O si ntan awọn ti ngbe ori ilẹ̀ ayé jẹ nipa awọn ohun iyanu ti a fi fun un lati ṣe niwaju ẹranko naa; o nwi fun awọn ti ngbe ori ilẹ ayé lati yá aworan fun ẹranko naa ti o ti gba ọgbẹ́ idà, ti o si yè. (Ifh 12:9; 2 Tess 2:9,10.)

15. A si fi fun un, lati fi ẹ̀mí fun aworan ẹranko naa ki o maa sọ̀rọ̀ ki o si mu ki a pa gbogbo awọn ti kò foribalẹ fun aworan ẹranko naa. (Dan 3:5; Ifh 16:2.)

16. O si mu gbogbo wọn, ati kekere ati nla, ọlọ́rọ̀ ati talaka, ominira ati ẹrú, lati gba àmì kan si ọwọ́ ọ̀tún wọn, tabi ni iwaju orí wọn; (Ifh 11:18; 19:5,18; 14:9.)

17. Ati ki ẹnikẹni má lè rà tabi tà, bikoṣe ẹni ti o ba ni àmì naa, eyi ni orukọ ẹranko naa, tabi nọmba orukọ rẹ̀. (Ifh 14:9; 11:15,2.)

18. Nihin ni ọgbọ́n gbe wà. Ẹni ti o ba ní òye, ki o *ka nọmba ti nbẹ lára ẹranko naa: nitori pé nọmba eniyan ni, nọmba rẹ̀ naa sì jẹ́ ẹgbẹ̀ta ọgọ́ta ẹ́ẹ́fà (600 60 6). (Ifh 17:9; 15:2; Psm 107:43.)

## ORI 14.

**Ọ̀dọ́-Agutan naa lori òkè Sioni.**

MO si wo, si kiyesi i, Ọdọ-Agutan naa duro lori òkè Sioni, ati pẹlu rẹ̀ ọ̀kẹ́ meje o le ẹgbaaji eniyan; wọn ni orukọ Rẹ̀, ati orukọ Baba Rẹ̀ ti a kọ si iwaju-orí wọn, (Ifh 5:6; Psm 2:6; Ifh 3:12; 7:3; Heb 12:22,23.)

2. Mo si gbọ ohùn kan lati ọ̀run wá, bi ariwo omi pupọ, ati bi sísán ààrá nlá: mo sì gbọ́ awọn oniharpu, nlu harpu wọn. (Ifh 1:15; 5:8.)

3. Wọn si nkọ bi ẹni pé orin tuntun niwaju ìtẹ́ naa, ati niwaju awọn ẹ̀dá alààyè mẹrin naa, ati awọn àgbà naa: kò sì sí ẹni ti o lè kọ orin naa, bikoṣe awọn ọ̀kẹ́ meje o lé ẹgbaaji eniyan, ti a ti rà padà lati inu ayé wá. (Ifh 5:9.)

4. Awọn wọ̀nyí ni a kọ́ fi obinrin sọ di èérì: nitori ti wọ́n jẹ́ wundia. Awọn wọ̀nyí ni o ntọ Ọ̀dọ́-àgùntàn naa lẹ́yìn nibikíbi ti o bá nlọ. Awọn wọ̀nyí ni a rà padà lati inú awọn eniyan wá, wọ́n jẹ́ àkọ́so fun Ọlọrun ati fún Ọ̀dọ́-àgùntàn naa. (Jak 1:18; Rom 8:23.)

5. A ko si ri èké lẹnu wọn, wọn jẹ́ alailabuku. (Psm 32:2; Sef 3:13; Ef 5:27.)

(18) *'Ka nọmba' (chashab) ni ọ̀rọ̀ naa wí ni ede Griki, kìí ṣe 'rò̀ó pọ̀' (add up) gẹgẹ bi awọn bibeli mìran ti ṣe ninu bibeli wọn. Kika nọmba naa ni eyi ti a kọ sìhin yìí, kìí ṣe ọtale-lẹgbẹta o le mẹfa (666) bi awọn bibeli naa ti kọ ọ́. Nọmba naa si ni itumọ ijinlẹ kan ti a fi ọgbọn ati oye Ọlọrun mọ.

**Angẹli ti oun ti ihinrere ainipẹkun.**

6. Mo sì rí angẹli miran nfò ni aarin méji ọ̀run, pẹlu Ihinrere ainipẹkun lati wàásù fun awọn ti ngbe orí ilẹ̀ ayé, ati fun gbogbo orilẹ, ati ẹ̀yà, ati èdè, ati eniyan. (Ifh 8:13; 3:10; 5:9.)

7. O nwi ni ohun rara pe, "Ẹ bẹ̀rù Ọlọrun, ki ẹ si fi ogo fun un, nitori ti wakati idajọ rẹ̀ dé: ẹ si foribalẹ fun ẹni ti o dá ọ̀run, ati ayé, ati òkun, ati awọn orísun omi!"

**Angẹli keji nkede iṣubu Babiloni nla.**

8. Angẹli miran si tẹle e, o nwi pé, "O ṣubu, Babiloni nla ṣubu, èyí tí o ti nmú gbogbo orilẹ-èdè mu ninu ọti-waini àìmọ́ àgbèrè rẹ̀!" (Ifh 18:1–5.)

**Angẹli kẹta nkede ìkìlọ lati má sìn Aṣòdìsí-Kristi.**

9. Angẹli miran, ẹkẹta, si tẹ̀lé wọn, o nwi ni ohun rara pé, "Bí ẹnikẹni bá nforibalẹ fun ẹranko naa ati aworan rẹ̀, ti o si gba àmì si iwaju orí rẹ̀ tabi si ọwọ́ rẹ̀,

10. Oun pẹlu yoo mu ninu ọti-waini ibinu Ọlọrun, ti a dà laini àbùlà sinu ago ìrunú rẹ̀; a o si fi iná sulfuru dá a loro niwaju awọn angẹli mímọ́, ati niwaju Ọdọ-Agutan:

11. Eefin ìdálóró wọn nlọ soke titi laelae wọn kò sì ni isinmi ni ọ̀sán ati ni òru, awọn ti nforibalẹ fun ẹranko naa ati fun aworan rẹ̀, ati ẹnikẹni ti o ba si gba àmì orukọ rẹ̀."

12. Nihin ni suuru awọn eniyan-mímọ́ gbé wà: awọn ti npa ofin Ọlọrun ati igbagbọ Jesu mọ́.

**Lati ìgbàyí lọ òkú ninu Oluwa jẹ alabùkún.**

13. Mo si gbọ́ ohùn kan lati ọ̀run wá nwi fun mi pé, "Kọwe rẹ̀, Alabukun fún ni awọn òkú tí o kú ninu Oluwa lati ihin lọ." Alabukun ni wọn nitootọ́, bẹẹ ni, Ẹmi wí, "Nitori tí wọn yoo, sinmi kúrò ninu làálàá wọn, nitori iṣẹ́ wọn ntọ̀ wọn lẹ́hìn."

**Ipadabọ Jesu lẹ̀ẹkeji lati gba awọn eniyan rẹ̀ mímọ́ sọdọ rẹ̀.**

14. Mo si wo, si kiyesi i, ikuukuu

awọsanma funfun kan, ati lori ikuukuu àwọsánmà naa ẹnikan jokòó ti o dabi Ọmọ ènìyàn, ti oun ti adé wúrà ní orí rẹ̀, ati dòjé mímú ni ọwọ́ rẹ̀.

15. Angẹli miran si ti inu tẹmpili jade wa ti nke lóhùn rara si ẹni ti o jokòó lori ikuukuu awọsanma naa pe, "Tẹ dòjé rẹ bọ̀ ọ́, ki o si maa kórè: nitori àkókò ati kórè dé, nitori ìkórè ayé ti gbó tán."

16. Ẹni tí o jokòó lori ikuukuu awọsanma naa si tẹ dòjé rẹ̀ bọ orí ilẹ̀ ayé; a si ṣe ìkórè ilẹ̀ ayé.

**Kikore gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ aye jọ sinu ifunti nla Ibinu Ọlọrun.**

17. Angẹli miran si ti inu tẹmpili ti nbẹ ni ọ̀run jade wá, oun pẹlu si ni dòjé mímú, kan.

18. Angẹli miran si ti ibi pẹpẹ jade wá, ti o ni agbara lori iná; o si ké ni ohùn rara si ẹni ti o ni dòjé mímú naa, wi pe, "Tẹ dòjé rẹ mímú bọ ọ, ki o si ré awọn ìdí àjàrà ayé, nitori awọn èso ré ti pọ́n."

19. Angẹli naa si tẹ dòjé rẹ̀ bọ ilẹ̀ ayé, o si ge àjàrà ilẹ̀-ayé, o si ko o lọ sinu ìfúntí, ìfúntí nla ibinu Ọlọrun.

20. A si tẹ ìfúntí naa lẹhin òde ilu naa, ẹ̀jẹ̀ si ti inu ìfúntí naa jáde, o si ga sókè de okùn ìjánu ẹṣin, eyi ti ìnàsílẹ̀ rẹ to ẹgbẹjọ ibusọ.

## ORI 15.

**Àmì nla kan ati awọn Angẹli meje ti o ni ìyọnu meje.**

MO sì ri àmì miran ni ọrun ti o tobi ti o si yanilẹnu, awọn angẹli meje ti o ni awọn ìyọnu meje ikẹhin, nitori ninu wọn ni ibinu Ọlọrun de opin. (Ifh 12:1,3; 16:1; Lef 26:21; Ifh 14:10.)

**Awọn eniyan-mimọ ti o ti ṣẹgun ti a si gba soke (Ijọ Ọlọrun).**

2. Mo sì ri bi ẹni pe òkun dígí ti o dàpọ̀ pẹlu iná: awọn ti o si duro lori òkun dígí yìí jẹ́ àwọn ti wọn ti ṣẹgun ẹranko naa, ati aworan rẹ̀, ati àmì rẹ̀ ati nọmba orukọ rẹ̀, wọn ní harpu Ọlọrun. (Ifh 4:6; 13:14,15; 5:8.)

3. Wọn si nkọ orin ti Mose, iranṣẹ Ọlọrun, ati orin ti Ọdọ-Agutan, wi pe, "Titobi ati ìyanu ni awọn iṣẹ́ rẹ, Oluwa Ọlọrun Olodumare; ododo ati otitọ ni ọ̀nà rẹ̀, iwọ Ọba awọn orilẹ-èdè. (Deut 32:3,4; Psm 111:2; 145:17; Hos 14:9.)

4. Tani ki yoo bẹ̀rù, Oluwa, ti ki yoo sì fi ogo fun orukọ rẹ̀? Nitori iwọ nikanṣoṣo ni mímọ́: gbogbo awọn orilẹ-èdè ni yoo sì wá, ti yoo si foribale niwaju rẹ: nitori a ti fi ìdájọ́ rẹ hàn." (Jer 10:7; Isa 66:23.)

**Awọn Angẹli naa gba agbada ibinu Ọlọrun.**

5. Lẹhin naa mo si wo, si kiyesi i, a ṣi tẹmpili àgọ́ ẹ̀rí ni ọrun sílẹ̀: (Ifh 11:19; Num 1:50.)

6. Awọn angẹli meje naa si ti inú tẹmpili jade wá, wọn ni ìyọnu meje naa, a wọ̀ wọn ní aṣọ ọ̀gbọ̀ funfun ti ndán, a si fi àmùrè wura di wọn ni ookan àyà. (Ifh 14:15; ẹsẹ 1; Ifh 1:13.)

7. Ati ọ̀kan ninu awọn ẹ̀dá alààyè mẹrin naa fi agbada wura meje fun awọn angẹli meje naa, ti o kún fún ìbínú Ọlọrun, ẹni ti nbẹ láàyè lae ati laelae. (Ifh 4:6,9; 10:6.)

8. Tẹmpili naa si kún fun eefin lati inu ògo Ọlọrun ati agbara rẹ̀ wá; ẹnikẹni kò sì lè wọ inu tẹmpili naa lọ titi a fi mú ìyọnu mejeeje awọn angẹli meje naa ṣẹ. (Eks 40:34; 1 A.Ọba 8:10; Isa 6:4.)

## ORI 16.

MO si gbọ́ ohùn nla kan lati inú tẹmpili wá, nwi fun awọn angẹli meje naa pe, "Ẹ lọ, ẹ si tu agbada ibinu Ọlọrun naa si orí ilẹ̀ ayé!" (Ifh 15:1.)

**Agbada ibinu kinni: egbò kíkẹ̀ sara eniyan.**

2. Ekinni si lọ, o si da agbada tirẹ̀ si orí ilẹ̀ ayé; egbò kíkẹ̀ ti o si dibajẹ si dá awọn eniyan ti o ní àmì ẹranko naa, ati awọn ti nforibalẹ fun àwòrán rẹ̀. (Ifh 8:7; Eks 9:9–11; Ifh 13:15–17.)

**Agbada ibinu keji: òkun dabi ẹ̀jẹ̀.**

3. Ekeji si da agbada tirẹ̀ sinu òkun; o si dabi ẹ̀jẹ̀ òkú eniyan: gbogbo alààyè ọkàn si kú ninu òkun. (Ifh 8:8,9; Eks 17:17–21.)

**Agbada ibinu kẹta: odò ati orísun omi di ẹ̀jẹ̀.**

4. Ẹkẹta si da agbada tirẹ̀ sinu odò, ati sí orísun awọn omi; wọn si di ẹ̀jẹ̀. (Ifh 8:10; Eks 7:17–21.)

5. Mo si gbọ́ angẹli ti omi wi pé, "Olododo ni Iwọ, Ẹni Mímọ́, ẹni ti o nbẹ, ti o si ti wà, nitori tí iwọ ṣe ìdájọ́ bayìí. (Ifh 15:3; 11:17; 15:4.)

6. Nitori ti wọn ti ta ẹ̀jẹ̀ awọn eniyan-mímọ́ ati ti awọn woli sílẹ̀, iwọ si fi ẹ̀jẹ̀ fún wọn mu; èyí ni o yẹ wọ́n." (Ifh 17:6; 18:24; Isa 49:26.)

7. Mo si gbọ́ pẹpẹ nke wi pe, "Bẹẹni, Oluwa Ọlọrun Olodumare, otitọ ati ododo ni ìdájọ́ rẹ!" (Ifh 6:9; 14:18; 15:3; 19:2.)

**Agbada ibinu kẹrin: òòrùn nfi iná jo gbogbo eniyan lara.**

8. Ẹkẹrin si da agbada tirẹ sórí òòrùn: a si yọnda fun un lati fi iná jo eniyan lara. (Ifh 8:12; 14:18.)

9. A si fi oorùn nla jó awọn eniyan lara, wọn si sọ̀rọ̀ òdì si orukọ Ọlọrun. Ẹni ti o ni agbara lori ìyọnu wọnyìí; wọn kò si ronupiwada lati fi ogo fun un. (Ifh 2:21; 11:13.)

**Agbada ibinu karun: òkùnkùn.**

10. Ẹkarun si da agbada tirẹ̀ sórí ìtẹ́ ẹranko naa; ijọba rẹ̀ si ṣókùnkùn; wọn si nge ahọ́n wọn jẹ nitori irora. (Ifh 9:1–11.)

11. Wọn si sọ̀rọ̀ òdì sí Ọlọrun ọ̀run nitori irora wọn ati nitori egbò wọn, wọn kò si ronupiwada iṣẹ́ wọn. (ẹsẹ 9:21; Ifh 11:13; 2:21.)

**Agbada ìbínú kẹfa: ẹ̀mí aìmọ́ mẹta ti ẹ̀ṣù nmura silẹ de Armageddoni.**

12. Ẹkẹfa si da agbada tirẹ sórí odò-nla Eufrate; omi rẹ̀ si gbẹ, ki a le pèsè ọ̀nà fún awọn ọba lati ìlà-òòrùn wá. (Ifh 9:14; Isa 41:2.)

13. Mo si ri awọn ẹ̀mí àìmọ́ mẹta bi ọ̀pọ̀lọ́, wọn ti ẹnu dragoni naa ati ẹnu ẹranko naa, ati ẹnu woli èké naa jade wá. (Ifh 12:3; 13:1; 19:20.)

14. Nitori ẹ̀mí èṣù ni wọ́n, ti nṣe iṣẹ́-iyanu, awọn ti njade lọ sọdọ awọn ọba gbogbo ilẹ̀-ayé, lati gbá wọn jọ si ogun ọjọ́ nla Ọlọrun Olodumare. (1 Tim 4:1; Ifh 13:13; 3:10; 17:14.)

15. ("Kiyesi i, mo nbọ̀ bi olè. Ibukun ni fun ẹni ti nṣọ́nà, ti o si npa aṣọ rẹ̀ mọ́, ki o ma baa rìn ni ìhòhò, wọn a si ri ìtìjú rẹ̀.") (1 Tess 5:2; 2 Kor 5:3.)

16. O si gbá wọn jọ si ibikan ti a npe ni Armageddoni ni èdè Heberu. (Ifh 19:19; 9:11; 2 A.Ọba 23:29,30.)

**Agbada keje: ìṣẹ̀lẹ̀ nla.**

17. Ekeje si da agbada tirẹ̀ si oju ọrun; ohùn nla kan si ti inú tẹmpili jade lati ibi ìtẹ́, wi pe, "O parí!" (Ef 2:2; Ifh 11:15; 14:15; 21:6.)

18. Mànàmáná si kọ, a si gbọ ohùn, ààrá si sán, ìmimi-ilẹ̀ nla si mi, irú èyí ti kò si rí lati ìgbà ti eniyan ti wà lórí ilẹ̀, irú imimì-ilẹ̀ nla bẹẹ ti o si lagbara ti o si papọju. (Ifh 6:12; Dan 12:1.)

19. Ilú nla naa si pin si ipa mẹta, awọn ìlú awọn orilẹ-èdè si ṣubú: Babiloni nla si wá si iranti, iranti niwaju Ọlọrun, lati fi ago ọtí-waini ti ìrúnú ibinu rẹ̀ fun un. (Ifh 17:18; 14:8; 18:5; 14:10.)

20. Olukuluku erékùṣù si salọ, akò si rí awọn òkè-nla mọ́. (Ifh 6:14.)

21. Yìnyín nla ti ọ̀kọ̀ọkan rẹ̀ tó talẹnti ni ìwọ̀n si bọ́ lu awọn eniyan lati ọrun wá: awọn eniyan si sọ̀rọ̀ òdì si Ọlọrun nitori ìyọnu yìnyìn naa; nitori ti ìyọnu rẹ̀ naa pọ gidigidi. (Ifh 11:19; Eks 9:23.)

ORI 17.

**Babiloni nla Panṣaga-obinrin.**

OKAN ninu awọn angẹli meje naa ti o ni ìgò meje naa si wá, o si ba mi sọ̀rọ̀ wi pe, "Wa nihin; emi o si fi idajọ panṣaga-obinrin nla naa, ti o joko lori omi pupọ hàn ọ́: (Ifh 21:9; 16:19; 19:2; Jer 51:13.)

2. Ẹni tí awọn ọba ayé bá ṣe àgbèrè,

ti a sì ti fi ọti-waini àgbèrè rẹ̀ pa awọn ti ngbe inu ayé." (Ifh 18:3; 14:8.)
3. O si gbe mi ninu Ẹmí lọ si aginjù: mo sì rí obinrin kan o jókòó lori ẹranko aláwọ̀ òdòdó kan ti o kún fún orukọ ọ̀rọ̀-òdì, oun ní orí meje ati ìwo mẹwa. (Ifh 12:3,6,14.)
4. A si fi aṣọ elésè àlùkò ati aṣọ òdòdó wọ obinrin naa, a si fi wúrà ati okuta iyebiye ati perli ṣe e lọṣọ, o ni ago wúrà kan lọ́wọ́ rẹ̀, ti o kun fún ìrira ati fun ẹ̀gbin agbere rẹ̀: (Jer 51:7; Ifh 18:16; 18:6.)
5. Ati niwaju rẹ̀ ni a kọ, orukọ ohun-ijinlẹ "BABILONI NLA, ÌYÁ AWỌN PANṢAGA-OBINRIN ATI AWỌN OHUN IRIRA AYÉ". (2 Tess 2:7; Ifh 14:8; 16:19; 18:9.)
6. Mo si ri obinrin naa mu ẹ̀jẹ̀ awọn eniyan-mímọ́, ati ẹ̀jẹ̀ awọn ajẹrikú Jesu ni àmuyó: nigba ti mo si ri i, ẹnu yà mí gidigidi. (Ifh 18:24; 13:15; 12:11.)

**Ohun ijinlẹ ti panṣaga-obinrin naa ati ẹranko naa ni a tumọ rẹ̀.**

7. Angẹli si wi fun mi pé, "Nitori kinni ẹnu ṣe yà ọ́? Emi o sọ ti ìjìnlẹ obinrin naa fun ọ, ati ti ẹranko ti o gùn, ti o ni orí meje ati ìwo mẹwa. (ẹsẹ 5:3,9.)
8. Ẹranko ti iwọ ri naa, o ti wà, kò sì sí mọ́: yoo si ti inu ọ̀gbun goke wá, yoo si lọ sinu ègbé: ẹnu yoo si ya awọn ti ngbe orí ilẹ̀ ayé, orukọ awọn ẹni ti a ko kọ sinu iwe ìyè lati ìpilẹ̀ṣẹ̀ ayé, nigba ti wọn nwo ẹranko ti ó ti wà, ti kò sì sí mọ́, ti o si nbọ̀wá (Ifh 11:7; 13:1; 3:10.)
9. Nihin ni itumọ ti o ni ọgbọ́n wà. Orí meje yìí ni oke nla meje lórí èyí tí obinrin naa jókòó. (Ifh 13:18.)
10. Ọba meje si ni wọ́n: awọn marun ṣubú, ọ̀kan nbẹ, ọ̀kan ìyókù kò sì tîì dé; nigba ti o ba si dé, yoo duro fun ìgbà kukuru.
11. Ẹranko ti o si ti wà, ti kò sì sí, oun naa si ni ẹkẹjọ o si ti inu awọn meje naa wá, o si lọ si iparun. (ẹsẹ 8.)
12. Ìwo mẹwa ti iwọ sì rí naa ọba mẹwa ni wọ́n, ti wọn kòì tîì gba àṣẹ ọba; ṣugbọn wọn yoo gba ọlá aṣẹ bi ọba pẹlu ẹranko naa fun wakati kan. (Dan 7:20; Ifh 13:1; 18:10,17,19.)
13. Awọn wọnyìí ní inú kan, wọn o si fi agbara ati ọlá wọn fún ẹranko naa. (ẹsẹ 17.)
14. Awọn wọnyìí ni yoo si bá Ọ̀dọ́-Agutan, naa jagun, Ọ̀dọ́-Agutan naa yoo si ṣẹgun wọn: nitori oun ni Oluwa awọn oluwa, ati Ọba awọn ọba: awọn ti o si wà pẹlu rẹ̀ ti a pè, ti a yàn ti wọn si jẹ olootọ yoo si ṣẹgun pẹlu." (Ifh 16:14; 1 Tim 6:15; Ifh 19:16; Matt 22:14.)
15. O si wi fun mi pé, "Awọn omi ti iwọ ri yìí nibi ti àgbèrè naa jókòó, awọn eniyan, ati ẹ̀yà, ati orilẹ, ati oniruuru èdè ni wọn. (Isa 8:7; Ifh 5:9; 13:7.)
16. Ati ìwo mẹwa ti iwọ rí, ati ẹranko naa, awọn wọnyìí ni yoo korira panṣaga-obinrin naa, wọn o si sọ ọ di ahoro ati ẹni ìhòhò, wọn o si jẹ ẹran ara rẹ̀, wọn o si fi iná sun un patapata. (Ifh 18:17,19; Esk 16:37,39; Ifh 19:18; 18:8.)
17. Nitori Ọlọrun ti fi sinu ọkàn wọn lati mú ifẹ rẹ̀ ṣẹ, lati ni inú kan, lati fi ijọba wọn fún ẹranko naa, títí ọ̀rọ̀ Ọlọrun yoo fi ṣẹ. (2 Tess 2:11; Ifh 10:7.)
18. Obinrin ti iwọ ri naa ni ilu-nla ti njọba lori awọn ọba ilẹ̀ ayé." (Ifh 16:19.)

## ORI 18.

**Ìkéde iṣubu Babiloni.**

LẸHIN nkan wọnyìí mo sì rí angẹli miran, o nti ọ̀run sọkalẹ wá pẹlu agbara nla; ilẹ̀ ayé si ti ipa ogo rẹ̀ mọ́lẹ̀. (Ifh 17:1; 10:1; Esk 43:2.)
2. O si kigbe ni ohùn rara, wí pé, "O ṣubu, Babiloni nla ṣubu, o sì di ibùjokòó awọn ẹ̀mí èṣù, ati ihò ẹ̀mí àìmọ́ gbogbo, ati ibùgbé ẹyẹ àìmọ́ ati ìrira gbogbo. (Ifh 14:8; Isa 13:21,22; Jer 50:39.)
3. Nitori nipa ọti-waini ìrunú àgbèrè rẹ̀ ni gbogbo awọn orilẹ-èdè ṣubú,

awọn ọba ayé si ti ba a ṣe àgbèrè, ati awọn oníṣòwò ayé si di ọlọ́rọ̀ nipa ọpọlọpọ wọbia rẹ̀." (Ifh 14:8; Jer 25:15,27.)

**Ìpè lati jade kúrò ninu Babiloni.**

4. Mo si gbọ́ ohun miran lati ọ̀run wá, nwi pé, "Ẹ jade kuro ni inú rẹ̀, èyin eniyan mi, ki ẹ ma baa ṣe alabapin ninu ẹ̀ṣẹ̀ rẹ̀, ki ẹ ma baa si ṣe gbà ninu ìyọnu rẹ̀. (Isa 48:20; Jer 50:8; 2 Kor 6:17.)

5. Nitori awọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ̀ ga titi dé ọ̀run, Ọlọrun si ti ranti aiṣedeede rẹ̀. (Jer 51:9; Ifh 16:19.)

6. San an fun un, àní bí oun ti san funni, ki o si ṣe e ni ilọpo meji fun un gẹgẹ bi iṣẹ́ rẹ̀: ninu ago naa ti o ti npòó oun ni ki ẹ ti pòó pọ̀ fun un ni ìlọ́po meji. (Psm 137:8; Jer 50:15; Ifh 14:10; 16:19.)

7. Niwọn bi o ti yin ara rẹ̀ logo tó, tí o si hùwà wọbia, niwọn bẹẹ ni ki ẹ daa lóró ki ẹ si fun ni ibanujẹ: nitori ti o wi ni ọkàn rẹ̀ pe, 'Mo jokòó bi ọbabinrin, emi kìí ṣii ṣe opó, emi ki yoo si rí ibanujẹ lae': (Esk 28:2–8; Isa 47:7,8; Sef 2:15.)

8. Nitori naa ni ọjọ́ kan ni ìyọnu rẹ̀ yoo de, ikú, ati ibanujẹ, ati ìyàn; a o si fi iná sun un patapata: nitori pé alagbara ni Oluwa Ọlọrun ti nṣe idajọ rẹ̀." (Isa 47:9; Ifh 17:16; Jer 50:34; Ifh 11:17.)

**Ipohunrere ẹkún lori Babiloni.**

9. "Ati awọn ọba ayé, ti o ti nba a ṣe àgbèrè, ti wọn si nba a hu ìwà wọbia, yoo si pohunrere ẹkún le e lórí, nigba tí wọn ba wo eefin ìjóná rẹ̀. (Ifh 17:2; Jer 50:46; ẹsẹ 18; Ifh 19:3.)

10. Wọn o duro ní òkèrè réré nitori ìbẹ̀rù iṣẹ oró rẹ̀, wọn o maa wi pe, "Ègbé, ni fun ilu-nla naa, Babiloni, ilu alagbara naa nitori ni wakati kan ni idajọ rẹ dé!" (ẹsẹ 15,17,16,19.)

11. Awọn oníṣòwò ayé si nsọkun, wọn si nṣọ̀fọ̀ lori rẹ̀; nitori pé ẹnikẹni kò ra ọjà wọn mọ́. (ẹsẹ 3; Esk 27:27.)

12. Ọjà wura, fàdákà, okuta iyebiye, perli, aṣọ ọ̀gbọ̀ wíwẹ̀, elésè àlùkò, ṣẹ́dà, òdòdó, onírúurú igi olorun dídùn, gbogbo ohun-èlò ti ehín-erin, gbogbo ohun-èlò tí a fi igi iyebiye ṣe, ti idẹ, irin, okuta marbili, (Ifh 17:4.)

13. Ati ti kinamoni, ti oniruuru ohun olóorùn dídùn, ohun ikunra, turari, ọti-waini, òróró, ìyẹ̀fun daradara, alikama, malu, agutan, ẹṣin, kẹ̀kẹ́, ati ẹrú, tii ṣe ọkàn eniyan. (Esk 27:13.)

14. Ati awọn èso ti ọkàn rẹ̀ nṣe ifẹkufẹ sí, si lọ kúrò lọdọ rẹ̀, ati ohun gbogbo ti o dùn ti o si dara ṣègbé mọ ọn lójú, ki yoo si tun rí wọn mọ lae.

15. Awọn oníṣòwò nkan wọnyìí, ti a ti ipa rẹ̀ sọ di ọlọ́rọ̀, yoo duro ni òkèrè réré nitori ìbẹ̀rù iṣẹ́ oró rẹ̀, wọn o maa sọkun, wọn o si maa ṣọ̀fọ̀. (Esk 27:36,31.)

16. Wi pe, 'Ègbé, Ègbé ni fun ilu-nla naa ti a wọ ni aṣọ ọ̀gbọ̀ wíwẹ̀, ati ti elésè àlùko, ati ti òdòdó, ati ti a si fi wúrà ṣe lọ́ṣọ̀ọ́, pẹlu okuta iyebiye ati perli!' (Ifh 17:4.)

17. Nitori pé ni wakati kan ni ọrọ̀ ti o pọ tobẹẹ di asán." Ati olukuluku ẹni ti nrin ojú omi lọ si ibikibi, ati awọn ti nṣiṣẹ ninu oko, ati awọn ti nṣòwò ojú òkun duro ni okere réré. (Ifh 17:16; Isa 23:14; Esk 27:29.)

18. Wọn si kigbe nigba ti wọn ri eefin jíjóná rẹ̀, wi pe, 'Ìlú wo ni o dabi ilu-nla yìí?' (Esk 27:30; Ifh 13:4.)

19. Wọn si ku ekuru si orí wọn, wọn kigbe, wọn sọkun, wọn si nṣọ̀fọ̀, wi pe, 'Ègbé Ègbé, ni fun ilu-nla naa, ninu èyí tí a sọ gbogbo awọn ti o ni ọkọ̀ òkun di ọlọ́rọ̀ nipa ohun iyebiye rẹ̀; nitori pé ní wakati kan, a sọ ọ di ahoro.'" (Jos 7:6; Job 2:12; Esk 27:30.)

**Ayọ̀ wa ni ọ̀run nitori ìṣubú Babiloni.**

20. "Yọ̀ lori rẹ̀ ìwọ ọ̀run, ati èyin eniyan-mimọ ati ẹyin aposteli mímọ́ ati ẹyin woli; nitori Ọlọrun ti gbèsan yín lara rẹ̀!" (Isa 44:23; Jer 51:48; Ifh 19:2.)

**Apẹẹrẹ Iṣubu Babiloni.**

21. Angẹli alagbara kan si gbe okuta kan sókè, o dabi ọlọ nlá, o si ju u sínú òkun, wi pe, "Bayìí ni a o fi

agbara nla bi Babiloni ilu-nla naa wó, a ki yoo si ri i mọ lae. (Jer 51:63; Ifh 12:8.)

22. Ati ohùn awọn oniharpu, ati ti awọn olórin, ati ti awọn afunfèrè ati ti awọn afunpe ni a ki yoo si gbọ ninu rè mọ rárá; ati olukuluku onișọ̀nà ohunkóhun ni a ki yoo si ri ninu rè mó lae ati ìró ọlọ ni a ki yoo si gbó mó ninu rè lae. (Isa 24:8; Esk 20:13; Jer 25:10.)

23. Ati imọlẹ fitila ni ki yoo si tàn ninu rè mọ́ lae; a ki yoo si gbọ ohùn ọkọ iyawo ati ti iyawo ninu rè mọ́ lae; nitori pe awọn onișòwò rè ni awọn ẹni nla ayé: nitori pé nipa ọṣó rè ni a fi tan orilẹ-èdè gbogbo jẹ; (Jer 25:10; 7:34; 16:9; Isa 23:8; Nah 3:4.)

24. Ati ninu rè ni a gbe rí èjè awọn woli, ati ti awọn eniyan-mímọ́, ati ti gbogbo awọn ti a pa lori ilè ayé."

## ORI 19.

**Orin ìyìn fun Ọlọrun nitori idajọ rè: ati ti àsè alẹ ti igbeyawo Ọdọ-Agutan.**

LẸHIN nkan wọnyìí mo gbọ ohùn nla ni ọ̀run bi ẹni pé ti ọpọlọpọ eniyan, nwi pe, "Hallelujah; ti Oluwa Ọlọrun wa ni ìgbàlà, ati ọlá ati agbára. (Ifh 11:15; 4:11; 7:10,12; 12:10.)

2. Nitori otitọ ati ododo ni idajọ rè: nitori o ti ṣe idajọ panṣaga-obinrin nla naa, ti ó fi àgbèrè rẹ ba ilè ayé jé, o si ti gbèsan èjè awọn iranṣẹ rè lọwọ rè!" (Deut 32:43; Ifh 6:10.)

3. Ati lẹẹkeji wọn wi pé, "Hallelujah! Eefin rè si goke lọ lae ati laelae!" (Isa 34:10; Ifh 14:11.)

4. Awọn àgbà mẹrinlelogun naa ati awọn èdá alààyè mẹrin naa si wólè, wọn si foribalè fun Ọlọrun ti o jokòó lori ìté, wi pe, "Amin; Hallelujah!" (Ifh 4:4,6; 5:14.)

5. Ohùn kan si ti ibi ìté naa jade wá, wi pe, "Ẹ maa yin Ọlọrun wa, èyin iranṣẹ rè gbogbo, ẹyin ti o bèrù rè, ati èwe ati àgbà." (Psm 134:1; Ifh 11:18; 20:12.)

6. Mo si gbọ bi ẹnipé ohùn ọpọlọpọ eniyan, ati bi ìró omi púpọ̀, ati bí ìró àárá nlanla nwi pe, "Hallelujah: nitori Oluwa Ọlọrun wa, Olodumare njọba. (Ifh 11:15,17; 14:2.)

7. Ẹ jẹ ki a yọ̀, ki inú wa sì dùn gidigidi, ki a si fi ogo fun un nitori pé igbeyawo Ọdọ-Agutan dé, aya rè siti mura tán. (Matt 22:2; 25:10; 2 Kor 11:2; Ef 5:32; Ifh 21:2,9.)

8. A sì fifun un pé ki o wọ aṣọ ọ̀gbọ̀ wíwé ti o funfun gbòò:, nitori pe aṣọ ọ̀gbọ̀ wíwé naa ni òdodo awọn eniyan-mímọ́." (Ifh 15:4.)

9. O si wi fun mi pé, "Kọ̀wé rè, Ibukun ni fun awọn ti a pe si àsè-alé igbeyawo Ọdọ-Agutan." O si wi fun mi pe, "Wọnyìí ni ọ̀rọ̀ otitọ́ Ọlọrun." (ẹsẹ 10; Ifh 1:19; Luk 14:15; Ifh 21:5.)

10. Mo si wólè ni ẹsè rè lati foribalè fun un, O si wi fun mi pé, "Wo o, máṣe bẹẹ: iranṣẹ ẹlẹgbẹ́ rẹ ni emi, ati ti awọn arakunrin rẹ ti wọn di èrí Jesu mú: foríbalè fún Ọlọrun: nitori pe èrí Jesu ni èmí isọtẹ́lè. (Ifh 22:8; A.A. 10:26; Ifh 22:9; 12:17.)

**Iṣẹgun lori ẹranko naa ati woli èké naa.**

11. Mo si ri ọrun ṣi silẹ, si wo o, ẹṣin funfun kan; ẹni ti o si joko lori rè ni a npe ni Olóododo ati Olóotọ́, ninu òdodo ni o si nṣe idajọ, ti o si njagun. (Ifh 15:5; 6:2; 3:14; Isa 11:4.)

12. Ojú rè dabi ọwọ́ iná, ati ni orí rè ni àwọn adé pupọ wa; o si ni orukọ kan ti a kọ, tí ẹnikẹni kò mọ̀, bikoṣe oun tikararè. (Ifh 1:14; 6:2; 2:17.)

13. A si wọ ọ ni aṣọ ti a tè bọ inu èjè: a si npe orukọ rè ní Ọ̀rọ̀ Ọlọrun. (Isa 63:2,3; Jhn 1:1.)

14. Awọn ogun ọ̀run ti a wọ̀ ní aṣọ ọ̀gbọ̀ wíwé; funfun ati mímọ́, si ntọ ọ lẹ́hìn lori ẹṣin funfun. (ẹsẹ 8.)

15. Ati lati ẹnu rè ni idà mímú ti jade, eyi ti yoo maa fi ṣa awọn orilẹede: oun o si maa fi ọ̀pá irin ṣe àkóso wọn: o si ntẹ ifunti ìrunú ati ibinu Ọlọrun Olodumare. (Isa 11:4; 2 Tess 2:8; Psm 2:9; Ifh 2:27; 14:19,20.)

16. Lara aṣọ rẹ̀ ati ní itan rẹ̀ ni orukọ kan wà ti a kọ: ỌBA AWỌN ỌBA, ATI OLUWA AWỌN OLUWA. (Dan 2:47; Ifh 17:14.)

17. Mo si ri angẹli kan dúró ninu òòrùn; o si fi ohùn rara kígbe, o nwi fun gbogbo awọn ẹyẹ ti nfo ni aarin-meji ọ̀run pé, "Ẹ wá, ẹ si kó ara yin jọ pọ̀ si àsè-alẹ́ nla Ọlọrun. (Ifh 8:13; Esk 39:17.)

18. Ki ẹ̀yin lè jẹ ẹran-ara awọn ọba, ati ẹran-ara awọn olori ogun, ati ẹran-ara awọn eniyan alagbara, ati ẹran awọn ẹṣin, ati ti awọn ti o jókòó lori wọn, ati ẹran-ara eniyan gbogbo, ati ti ominira, ati ti ẹrú, ati ti èwe ati ti àgbà." (Esk 39:18–20; Ifh 11:18.)

19. Mo si ri ẹranko naa ati àwọn ọba ayé, ati awọn ogun wọn ti a gbájọ lati ba ẹni ti o jokòó lori ẹṣin naa ati ogun rẹ̀ jagun. (Ifh 11:7; 16:14,16.)

20. A si mu ẹranko naa, ati woli èké naa pẹlu rẹ̀, ti o ti nṣe iṣẹ́ ìyanu niwaju rẹ̀, èyí tí o ti fi ntan àwọn ti o gba àmì ẹranko naa, ati àwọn ti nforibalẹ fún aworan rẹ̀ jẹ. Awọn mejeeji yìí ni a sọ láàyè sinu adágún iná ti nfi sulfuru jó. Ifh 16:13; 13:12; Dan 7:11; Ifh 20:10; 14:10; 21:8.)

21. Awọn ìyókù ni a si fi idà ẹni ti o jokòó lori ẹṣin naa pa, àní idà ti o ti ẹnu rẹ̀ jade: gbogbo awọn ẹyẹ si ti ipa ẹran-ara wọn yó. (ẹsẹ 11,19,15,17.)

## ORI 20.

**Fífi ẹ̀wọ̀n de Satani.**

MO sì ri angẹli kan nti ọrun sọkalẹ wá, pẹlu kọ́kọ́rọ́ ọ̀gbun, ati ẹ̀wọ̀n nla kan ni ọwọ́ rẹ̀. (Ifh 10:1; 1:18; 9:1.)

2. O si di dragoni naa mu, ejò àtijọ́ nì, ti i ṣe Èṣù, ati Satani, o si de e fùn ẹgbẹrun ọdún. (2 Pet 2:4; Jud 6; Ifh 12:9.)

3. O si gbe e sọ sinu ọ̀gbun naa, o sì ti i, o si fi èdìdí di i mọ ọn lórí, ki o ma baa tan awọn orilẹ-èdè jẹ mọ́ titi ọdún naa yoo fi pé: lẹhin èyí, a nilati tu u silẹ fun ìgbà diẹ. (Dan 6:17; Ifh 12:9.)

**Ẹgbẹrun ọdún ijọba Kristi.**

4. Mo sì rí awọn ìtẹ́, wọn si jókòó lori wọn, a sì fi idajọ fun wọn: bẹẹ ni ọkàn awọn ti a ti bẹ́ lórí nitori ẹ̀rí Jesu, ati nitori ọ̀rọ̀ Ọlọrun, ati awọn ti kò si foribalẹ fún ẹranko naa, ati fun aworan rẹ̀, tabi ti kò sì gba àmì rẹ̀ niwaju wọn ati ni ọwọ́ wọn; wọn si wà láàyè, wọn si jọba pẹlu Kristi ni ẹgbẹrun ọdún. (Dan 7:9,22,27; Ifh 6:9; 13:12.15,16; Rom 8:17; 2 Tim 2:12.Matt 19:28.29.)

5. Àwọn òkú iyoku kò wà láàyè mọ́ títí ẹgbẹrun ọdún naa yoo fi pé, Èyí ni ajinde ekinni. (Luk 14:14; Filp 3:11; 1 Tess 4:16.)

6. Olubukun ati mímọ́ ni ẹni ti o ní ipa ninu ajinde ekinni naa: lori awọn wọnyìí ikú keji kò ní agbara, ṣugbọn wọn o jẹ́ alufa Ọlọrun ati ti Kristi, wọn o si maa jọba pẹlu rẹ̀ ni ẹgbẹrun ọdún. (Ifh 14:13; 2:11; 21:8; 1:6.)

**Títú Satani silẹ fun ìgbà diẹ.**

7. Nigba ti ẹgbẹrun ọdun naa ba si pe, a ó tú Satani silẹ kuro ninu túbú rẹ̀. (ẹsẹ 2.)

8. Yoo si jade lọ lati maa tan awọn orilẹ-èdè ti nbẹ ni igun mẹrẹẹrin ayé jẹ, Gogu ati Magogu, lati gbá wọn jọ si ogun: awọn ti iye wọn dabi iyanrin òkun. (Esk 38:2; 39:1; Ifh 16:14; Heb 11:12.)

9. Wọn si goke la ibú ayé já, wọn si yi ibùdó awọn eniyan-mímọ́ ká ati ilu ayanfẹ naa: iná si ti ọrun sọkalẹ̀ wá, o si jó wọn run. (Esk 38:9,22; 39:6.)

10. A si wọ́ Èṣù ti o tàn wọn jẹ lọ sinu adágún iná ati sulfuru, nibi ti ẹranko ati woli èké naa gbe wà, a o si maa dá wọn lóró tọ̀sán-tòru lae ati lae-lae. (ẹsẹ 3,8.)

**Ìtẹ́ funfun nla kan – ati idajọ.**

11. Mo sì ri ìtẹ́ funfun nlá kan, ati ẹni ti o jokòó lori rẹ̀, niwaju ẹni ti ayé ati ọrun fò lọ; a ko si ri àyè fun wọn mọ. (Ifh 4:2; 21:1; Dan 2:35; Ifh 12:8; 2 Pet 3:7.)

12. Mo sì rí awọn òkú, ati èwe ati àgbà, wọn dúró niwaju ìtẹ́; a si ṣi awọn

iwe silẹ; a si ṣi iwe miran kan silẹ tiiṣe iwe ìyè; a si ṣe ìdájọ́ fún awọn òkú lati inú ohun ti a ti kọ sinu awọn iwé naa, gẹgẹ bi iṣẹ́ wọn. (Matt 16:27; Ifh 2:3; 22:12.)
13. Òkun si yọ̀nda awọn òkú ti nbẹ ninu rẹ̀; ati Ikú ati Isà-òkú si yọnda òkú ti o wa ninu wọn; a si ṣe idajọ wọn olukuluku gẹgẹ bi iṣẹ́ wọn. (Ifh 6:8; Isa 26:19; Ifh 2:23.)
14. Ati Ikú ati Isà-òkú ni a si sọ sínú adagun iná, Èyí ni ikú keji. (1 Kor 15:26; Ifh 6:8.)
15. Bi a bá sì ri ẹnikẹni ti a kò kọ orukọ rẹ̀ sinu iwe ìyè, a sọ ọ́ sinu adagun iná.

ORI 21.

**Ọrun titun kan ati ayé titun kan.**

MO sì rí ọ̀run titun kan ati ayé titun kan: nitori pé ọ̀run ti iṣaaju ati ayé iṣaaju ti kọja lọ; òkun ko sì sí mọ́. (Isa 65:17; 2 Pet 3:13; Ifh 20:11.)
2. Mo sì rí ilu mímọ́, Jerusalẹmu titun nti ọ̀run sọkalẹ̀ wá lati ọ̀dọ̀ Ọlọrun, ti a ti múra silẹ bí ìyàwó ti a ṣe lọ́ṣọ̀ọ́ fun ọkọ rẹ̀.(Esk 37:27; 2 Kor 6:16; Ifh 7:15.)
3. Mo si gbọ ohùn nla kan lati orí ìtẹ́ naa wa, nwi pé, "Kiyesi i, àgọ́ Ọlọrun wà pẹlu awọn eniyan, oun o si maa bá wọn gbé, wọn o si maa jẹ́ eniyan rẹ̀, ati Ọlọrun tikararẹ yoo wà pẹlu wọn, yoo si maa jẹ Ọlọrun wọn. (Heb 11:10; 12:22; Ifh 3:12.)
4. Ọlọrun yoo si nu omijé gbogbo nù kuro ni ojú wọn; ki yoo si sí ikú mọ́, tabi ọ̀fọ̀, tabi ẹkún, bẹẹ ni ki yoo sí irora mọ́: nitori pé ohun atijọ ti kọja lọ." (Ifh 7:17; 1 Kor 15:26; Ifh 20:14; Isa 35:10; 65:19.)
5. Ẹni ti o jókòó lori ìtẹ́ naa, si wi pé, "Kiyesi i, mo sọ ohun gbogbo di ọ̀tun!" O si wi fun mi pé, "Kọwe rẹ̀: nitori ọ̀rọ̀ wọnyìí ododo ati otitọ ni wọ́n." (Ifh 4:9; 20:11; Isa 43:19; Ifh 19:9.)
6. O si wi fun mi pé, "Ó parí. Emi ni Alfa ati Omega, ipilẹ̀ṣẹ̀ ati òpin. Emi o si fi omi fun ẹni ti oungbẹ ngbẹ lati orisun omi ìyè lọ́fẹ̀ẹ́. (Ifh 16:17; 1:8; 22:13; Jhn 4:10.)
7. Ẹni ti o ba ṣẹgun ni yoo jogun nkan wọnyìí; emi o si maa jẹ Ọlọrun rẹ̀, oun o si maa jẹ ọmọ mi. (Ifh 2:7; ẹsẹ 3.)
8. Ṣugbọn awọn ojo, ati alàigbagbọ, ati ẹni ìríra, ati apànìyàn, ati àgbèrè, ati oṣó, ati abọ̀rìṣà, ati awọn èké gbogbo, ni yoo ni ipa tiwọn ninu adágún ti nfi iná ati sulfuru jó: eyi tii ṣe ikú keji." (Heb 12:14; Ifh 22:15; 19:20; 2:11.)

**Jerusalẹmu, ilu titun naa.**

9. Ọkan ninu awọn angẹli meje, ti wọn ni agbada meje, ti o kún fun ìyọnu meje ìkẹhìn sì wá, o si ba mi sọ̀rọ̀ wí pé, "Wá nihin, emi o fi ìyàwó, aya Ọdọ-Agutan hàn ọ́." (Ifh 15:1, 6,7; 20:14.)
10. O si mu mi lọ ninu Ẹmí si òkè nla kan ti o si ga, o si fi ilú naa han mi, Jerusalẹmu mímọ́, ti nti ọ̀run sọkalẹ wá lati ọdọ Ọlọrun, (Ifh 1:10; Esk 40:2; Ifh 17:3.)
11. Ti o ni ogo Ọlọrun: ìmọ́lẹ̀ rẹ̀ si dàbí okuta iyebiye gidigidi, àní bí okuta jasperi, o mọ́ bi Kristali; (Ifh 15:8; 22:5; 4:6.)
12. O si ni odi nla ati giga, o si ni ẹnu-bode mejila, ati ni awọn ẹnubode naa angẹli mejila ati orukọ ti a kọ sara wọn tii ṣe orukọ awọn ẹ̀yà mejila ti awọn ọmọ Israẹli; (Esk 48:31–34; Ifh 7:4–8.)
13. Ni ìhà ìlà-òòrún ẹnu-bode mẹta; ni ìhà àríwá ẹnu-bode mẹta; ni ìhà gusu ẹnu-bode mẹta; ati ní ìhà ìwọ̀-òòrùn ẹnu-bode mẹta.
14. Odi ìlú naa si ni ìpìlẹ̀ mejila, ati lori wọn orukọ awọn Aposteli mejila ti Ọdọ-Agutan. (Matt 16:18; Ef 2:20.)

**Ìwọn ìlú naa.**

15. Ẹni ti o si nba mi sọ̀rọ̀ ni ọ̀pá-ìwọ̀n wúrà kan lati fi wọn ìlú naa ati awọn ẹnubode rẹ̀, ati odi rẹ̀. (Ifh 11:1.)
16. Ilu naa si wà ni ibu mẹrin lọgbọgba, gígùn rẹ̀ ati ìbú rẹ̀ si dọgba: o sì fi ọpá-ìwọ̀n naa wọn ìlú naa wò, o

jẹ ẹgbaafa ibusọ gígùn rẹ̀ ati ìbú rẹ̀, ati giga rẹ̀ si dọgba.

17. O si wọn odi rẹ̀ ó jẹ́ ogoje ìgbọ̀nwọ́ lé mẹrin, gẹ́gẹ́ bi ọ̀ṣùwọ̀n eniyan, bẹẹ ni ti angẹli naa.

18. A si fi jasperi mọ odi ìlú naa. ilu naa si jẹ kìkì wúrà, o dabi digi ti o mọ́ kedere. (ẹsẹ 11,19,21; Ifh 4:6.)

19. A fi oniruuru okuta iyebiye ṣe ìpìlẹ̀ ogiri ìlú naa lọ́ṣọ̀ọ́. Ìpìlẹ̀ ekinni jẹ́ jasperi; ekeji, safiru; ẹkẹta, kalkedoni ẹkẹrin, emeraldi. (Isa 54:11,12; ẹsẹ 11,18; Ifh 4:3.)

20. Ẹkarun, sadoniksi; ẹkẹfa, karneliani; ekeje, Krisoliti; ẹkẹjọ berli; ẹkẹsan, topasi; ẹkẹwa, Krisoprasu; ẹkọkanla, jakinti; ekejila, ametisti. (Ifh 4:3.)

21. Ẹnu-bodè mejeejila jẹ perli mejila: olukuluku ẹnu-bodè jẹ́ perli kan; ọ̀nà ìgboro ìlú naa si jẹ kìkì wúrà, ó dàbí dígí dídán. (ẹsẹ 15,25,18.)

**Ìmọ́lẹ̀ ìlú naa.**

22. Emi kò sì ri tẹmpili ninu rẹ̀: nitori pé Oluwa Ọlọrun Olodumare ni tempili rẹ̀, ati Ọdọ́-Agutan. (Jhn 4:21, 23; Ifh 1:8; 5:6.)

23. Ilu naa kò sì ni òòrùn, tabi òṣùpá, lati maa tan imọlẹ si i: nitori pé ogo Ọlọrun ni o ntan ìmọ́lẹ̀ si i, Ọdọ-Agutan si ni fitila rẹ̀.

24. Awọn orilẹ-èdè yoo si maa rin nipa ìmọ́lẹ̀ rẹ̀: awọn ọba ayé si nmú ogo wọn wá sinu rẹ̀. (Isa 60:3,5.)

25. A ki yoo si sé awọn ẹnu-bode rẹ̀ rárá ni ọ̀sán: nitori ki yoo si òru níbẹ̀. (Isa 60:11; Sek 14:7; Ifh 22:5.)

26. Wọn o si maa mú ogo ati ọlá awọn orilẹ-èdè wá sinu rẹ̀.

27. Ohun aláìmọ́ kan ki yoo si wọ inú rẹ̀ rárá, tabi ohun ti nṣiṣẹ irira ati èké; bikoṣe awọn ti a kọ sinu iwé ìyè Ọdọ́-Agutan. (Isa 52:1; Joel 3:17; Ifh 22:14.)

## ORI 22.

**Omi ìyè kan ti o mọ́ bi kristali.**

O si fi odò omi ìyè kan hàn mi, ti o mọ́ bi kristali, ti nti ibi ìtẹ́ Ọlọrun ati ti Ọdọ-Agutan jade wá, (Esk 47:1; Sek 14:8; Ifh 4:6.)

2. Ni aarin igboro rẹ̀, ati níhà ikinni keji odò naa, ni igi ìyè gbe wà, ti o maa nso oniruuru èso mejila, a si maa so èso rẹ̀ ni oṣoṣù: ewé igi naa si wà fun mímú awọn orilẹ-èdè laradá. (Gen 2:9; Ifh 2:7; Esk 47:12.)

3. Ègún ki yoo sì sí mọ: ìtẹ́ Ọlọrun ati ti Ọdọ-Agutan ni yoo si maa wà nibẹ; awọn iranṣẹ rẹ̀ yoo si maa sin in: (Sek 14:11; Ifh 7:15.)

4. Wọn o si maa ri ojú rẹ̀; orukọ rẹ̀ yoo si maa wà ni iwaju orí wọn. (Matt 5:8; Ifh 14:1.)

5. Òru ki yoo sí mọ́; wọn kò sì ní wa ìmọ́lẹ̀ fitila, tabi ìmọ́lẹ̀ òòrùn; nitori pé Oluwa Ọlọrun ni yoo tan ìmọ́lẹ̀ fun wọn: wọn o si maa jọba lae ati laelae. (Ifh 21:25,23; Dan 7:27.)

**Otitọ ati ododo ni ọ̀rọ̀ naa.**

6. O si wi fun mi pé, "Ododo ati otitọ ni ọ̀rọ̀ wọnyìí: Oluwa Ọlọrun ẹ̀mí awọn woli ni o si ran angẹli rẹ̀ lati fi ohun ti o nilati ṣẹlẹ̀ laipẹ yìí han awọn iranṣẹ rẹ̀." (Ifh 1:1; 19:19; 21:5.)

7. "Kiyesi i, emi nbọ kánkán! Ibukun ni fun ẹni ti npa ọ̀rọ̀ isọtẹlẹ inu iwe yìí mọ́!" (Ifh 3:11; 1:3.)

8. Emi Johanu ni ẹni ti o gbọ ti o si ri nkan wọnyìí. Nigba ti mo si gbọ ti mo sì ri, mo wolẹ̀ lati foribalẹ̀ niwaju ẹsẹ angẹli naa, ti o fi nkan wọnyìí hàn mi, (Ifh 1:1; 19:10.)

9. Nigba naa ni o wi fun mi pe, "Wo o, máṣe bẹẹ : iranṣẹ ẹlẹgbẹ́ rẹ ni èmi, ati ti awọn arakunrin rẹ woli, ati ti awọn ti npa ọ̀rọ̀ inu iwe yìí mọ́: foribalẹ fún Ọlọrun!" (Ifh 19:10; 1:1; ẹsẹ 10,18,19; Ifh 21:2.)

**Èrè nbẹ fun rere ati buburu.**

10. O si wi fun mi pé, "Máṣe fi èdìdí dí ọ̀rọ̀ isọtẹlẹ ti inu iwe yìí: nitori ìgbà kù si dẹ̀dẹ̀. (Dan 8:26; Ifh 1:3.)

11. Ẹni ti nṣe alaiṣootọ́, ki o maa ṣe alaiṣootọ ǹṣó: ati ẹni ti nṣe ẹlẹ́gbin, kí o maa ṣe ẹlẹ́gbin nṣo: ati ẹni ti nṣe olododo, ki o maa ṣe olododo ǹṣó: ati ẹni ti nṣe mímọ́, ki o maa ṣe mímọ́ nṣo:" (Dan 12:10; Esk 3:27.)

12. "Kiyesi i, emi nbọ̀ kánkán; èrè mi si nbẹ pẹlu mi, lati san fun olukuluku gẹgẹ bi iṣẹ́ rẹ̀ yoo ti ri. (Isa 40:10; Jer 17:10; Ifh 2:23.)

13. Emi ni Alfa ati Omega, ẹni iṣaaju ati ẹni ìkẹhìn, ìpilẹ̀ṣẹ̀ ati òpin (Ifh 1:8,17; 21:6.)

14. Ibukun ni fun awọn ti nfọ aṣọ wọn, ki wọn lè ni ànfàní lati wá si ibi igi ìyè naa, ati ki wọn lè gba awọn ẹnu-bode wọ inú ìlú naa.

15. Nitori ni ode ni awọn ajá gbé wà, ati awọn oṣó, ati awọn àgbèrè, ati awọn apànìyàn, ati awọn abọ̀riṣà, ati olukuluku ẹni ti o fẹran èké ti o si nhuwa èké." (Gal 5:19; Kol 3:6; Filp 3:2.)

**Aṣẹ isọtẹlẹ wá lati ọwọ́ Jesu Oluwa.**

16. "Emi Jesu ni o rán angẹli mi lati jẹri nkan wọnyìí fun yin ni ti awọn ìjọ. Emi ni gbòngbò ati irú-ọmọ Dafidi, ati ìràwọ̀ owurọ ti ntàn." (Ifh 1:1; 5:5; Sek 6:12; 2 Pet 1:19; Ifh 2:28.)

17. Ẹmí ati Iyàwó wí pé, "Maa bọ!" Ati ẹni ti o ngbọ ki o wi pé, "Maa bọ!" Ati ẹni ti oungbẹ ngbẹ ki o wá, ati ẹni ti o bá sì fẹ́, ki o gba omi ìyè naa lọ́fẹ̀ẹ́. (Ifh 2:7; 21:2; Isa 55:1; Ifh 21:6.)

18. Emi kìlọ̀ fun olukuluku ẹni to ngbọ́ ọ̀rọ̀ ìsọtẹ́lẹ̀ inú iwe yìí pé, bí ẹnikẹni ba fi kún wọn, Ọlọrun yoo fi kún awọn ìyọnu ti a kọ sinu ìwé yìí fun un. (Deut 4:2; Owe 30:6; Ifh 15:6: 16:21.)

19. Bi ẹnikẹni ba si mú kúrò ninu ọ̀rọ̀ iwe isọtẹlẹ yìí, Ọlọrun yoo si mu ipa tirẹ kuro ninu iwe ìyè, ati kuro ninu ìlú mímọ́ naa, ati kuro ninu awọn ohun ti a kọ sinu ìwé yìí.(Deut 12:32

20. Ẹni ti o jẹri nkan wọnyìí wi pe, "Nitootọ́ emi nbọ̀ kánkán;" "Amin, Maa bọ, Jesu Oluwa!" (Ifh 1:2; 2 Tim 4:8; Rom 16:20; 2 Tess 3:18.)

**Oore-ọfẹ Oluwa wa.**

21. Oore-ọfẹ Jesu Oluwa ki o wà pẹlu gbogbo awọn eniyan-mímọ́. Amin.